# Édẹnì ti Sàtánì

Jeffersonville, Indiana USA

Ojo 29, Osu kẹjo, Odun 1965

1 Ẹ jẹ ki a tẹriba. Ọlọrun wa, a dupẹ lọwọ Rẹ ni alẹ yii fun aye nla yii, lati tun wa ni Orukọ Jesu Oluwa, lati pade ọta wa, ọta Rẹ, ni ita ni aaye ogun; pẹlu Ọrọ, lati le e kuro lãrin awọn eniyan Rẹ; ki wọn le rii, lalẹ yii, Oluwa, Imọlẹ Ihinrere. Mo gbadura pe Iwọ yoo fi ororo oju kun oju wa, ki a le ṣi i si Otitọ; ki awa ki o le lọ kuro nihin, ni sisọ ninu ọkan wa pe, "Ọkàn wa ko ha gbina ninu wa bi O ti mba wa sọ'ro ni ọna?" Iwosan fun awon alaisan ati awon ti o ni iponju. Iwuri fun awọn ti o rẹwẹsi. Gbe awọn ọwọ alailera soke. Je ki a wo Wiwa ti Jesu Oluwa, eyiti a gbagbọ pe o sunmọ. A beere eleyi ni Orukọ Jesu. Amin.

E joko.

2 Emi yoo gbiyanju lati wa ni ṣoki ni alẹ yii, nitori Mo mọ pe ọpọlọpọ ti wa lati oriṣiriṣi awọn apakan ti orilẹ—ede, si … fun isin naa; tabi duro moju, diẹ lara yin, ti ẹ ni lati pada, fun boya ọna jinjin lati pada. Emi si dupe. Ni owurọ yii Mo fẹ gbọ Arakunrin Neville, funrarami. Mo si ti gbọ iwasu rẹ ni ọpọlọpọ awọn igba, ati pe Mo mo riri rẹ nigbakugba ti Mo ba gbọ. Ṣugbọn ni owurọ yii, ifiranṣẹ ti akoko yẹn, Mo mọ pe Mo Oluwa lo dari mi lati tẹtisi iyẹn ni owurọ yii. O dara pupọ! Mo si rii idi ti ẹyin naa ṣe fẹran lati wa gbọ iwasu rẹ. Ati pe yoo ṣe rere fun ọ nigbagbogbo, o da mi loju, lati tẹti si.

3 Mo n gbiyanju lati mu diẹ ninu awọn ibere ijomitoro mi loni; laaro yii ati losan oni. Mo tun ni ọpọlọpọ, pupọ, ọpọlọpọ lati ṣe. Ati Emi …

Gẹgẹ bi, Mo gbagbọ, Jetro ni o sọ fun Mose ni igba kan, o sọ pe, "O pọ ju fun ọ." Nitorina, a ti ni ọpọlọpọ awọn arakunrin nibi nitorii awọn iṣoro yin. Gbogbo wọn ni o si tọ, ati pe wọn jẹ awọn nkan ti o dara ti a ni lati tọju. Ati pe Emi yoo ṣeduro oluṣo aguntan wa, tabi Arakunrin Mann, ati awọn minisita ti Igbagbọ wa miiran nibi. O le tọ wọn lọ. Wọn yoo sọ fun ọ gangan ohun naa lati ṣe; diẹ ninu awọn eniyan, awọn ọmọ wọn; igbeyawo, tabi awọn nkan ti ko tọ. Ati pe awọn ọkunrin wọnyi le ṣe iranlọwọ fun ọ gẹgẹ bi—bi ẹnikẹni miiran, 'nitori wọn jẹ iranṣẹ Kristi. Ki o si lọ sọdọ wọn, o da mi loju pe wọn yoo ṣe—wọn yoo fun ọ ni iranlọwọ ti o nilo. Nko le de ọdọ gbogbo awọn ti o nilo iranlọwọ. Won po pupo, nibikibi ti o ba lọ. Wọn kan n pọ si ni, o rii. Ati pe—ati pe o fẹ de ọdọ gbogbo wọn, ṣugbọn o ko le ṣe. Ṣugbọn Mo n gbadura nigbagbogbo pe Ọlọrun, ni bakan, yoo ṣiṣẹ gbogbo rẹ daradara fun ọ.

4 Nisisiyi, lalẹ yii, a fẹ lọ si Iwe-mimọ, ki a ka ipin kan lati inu Genesisi, ori kẹta; ki n kan tọka sẹhin si diẹ ninu awọn nkan ti a ti sọrọ nipa rẹ, ni awọn igba atijọ, ki a rii boya Jesu Oluwa yoo fun wa ni diẹ diẹ si ohun ti a yoo mọ nigbati a ba jade. Mo gbadura—gbadura pe Oun yoo.

> *EJÒ sa ṣe alarekereke jù ẹranko igbẹ iyoku lọ ti OLUWA Ọlọrun ti dá. O si wi fun obinrin na pe, õtọ li Ọlọrun wipe, Ẹnyin kò gbọdọ jẹ gbogbo eso igi ọgbà?*
>
> *Obinrin na si wi fun ejò na pe, Awa a ma jẹ ninu eso igi ọgbà:*
>
> *Ṣugbọn ninu eso igi nì ti o wà lãrin ọgbà Ọlọrun ti wipe, Ẹnyin kò gbọdọ jẹ ninu rẹ̀, bẽli ẹnyin kò gbọdọ fọwọkàn a, ki ẹnyin ki o má ba kú.*
>
> *Ejò na si wi fun obinrin na pe, Ẹnyin ki yio ku ikú kikú kan.*
>
> *Nitori Ọlọrun mọ̀ pe, li ọjọ́ ti ẹnyin ba jẹ ninu rẹ̀, nigbana li oju nyin yio là, ẹnyin o si dabi Ọlọrun, ẹ o mọ̀ rere ati buburu.*
>
> *Nigbati obinrin na si ri pe, igi na dara ni jijẹ, ati pe, o si dara fun oju, ati igi ti a ifẹ lati mu ni gbọ́n, o mu ninu eso rẹ̀ o si jẹ, o si fi fun ọkọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, on si jẹ.*
>
> *Oju awọn mejeji si là, nwọn si mọ̀ pe nwọn wà ni ìhoho; nwọn si gán ewe ọpọtọ pọ̀, nwọn si dá ibantẹ fun ara wọn.*

5 Ki Oluwa fi … Awọn ibukun Rẹ si kika Ọrọ Rẹ. Bayi Emi yoo fẹ lati mu àkórí lalẹ yi, lati ibẹ, ki n pe ní: *Édẹnì ti Sàtánì.* Ohun ti kò dùn lati sọ, *Édẹnì ti Sàtánì.* Ni ọna kan, ó jọ ọrọ ti mo n sọ ni alẹ ọjọ Sundee to kọja, Mo gbagbọ, nipa Ajọ Eniyan Ti Nronu, ati itọwo eniyan mimọ.

Atipe nigbamiran awọn ọrọ kekeke ti ko dan mọran wọnyi mu wa si nkan; o jẹ ki a kọ ẹkọ, ki a si tẹra mọ kika Ọrọ naa. Ohun ti Mo si fẹ ki gbogbo ijọ mi ṣe ni yii. "Eniyan ki yio wa laye nipa akara nikan, bikoṣe nipa gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade wa." Nitorina, ka Ọrọ naa; kẹkọọ Rẹ. Ki o si kẹkọọ rẹ pẹlu oju Ọlọrun, lati fun okan rẹ ni oye bi o ṣe yẹ ki a gbe ni ọjọ yii.

6 Ni alẹ yii, lati ba yin sọrọ, Mo le wipe, "O dara, Mo le ṣe eyi tabi iyẹn, …"

Mo fẹran lati ba awọn eniyan sọrọ, gẹgẹ bi Mo fẹ lati paapaa lọ si ile pẹlu ọkọọkan yin ni alẹ yi. Emi … Ọlọrun mọ pe otitọ niyen. Emi yoo fẹ lati lọ si ile pẹlu ọkọọkan yin, lati jẹun aarọ pẹlu yin ni owurọ, ki n si jade lọ sọdẹ pẹlu yin ni ọsan ọla. Emi yoo fẹ lati ṣe bẹ, ṣugbọn Emi ko le ṣe bẹ. Emi yoo fẹ lati lọ si ile ki n kan joko lati ba ọ sọrọ; joko pẹlu ẹ lẹhin isin, funi igba diẹ, lati ba ọ sọrọ nipa ilera rẹ ati nipa Ọlọrun. Emi yoo fẹ lati ṣe bẹ. Awọn ọkunrin ati obinrin nihin; Ọlọrun mọ pe Emi yoo fẹ lati ṣe bẹ yẹn, ṣugbọn emi ko le ṣe. Wo, iru onfa ati igara yẹn wa

7 Ni awon ọjọ aifọkanbalẹ yii ti a n gbe ninu rẹ … Ati pe Mo jẹ eni ti ara rẹ kii balẹ. Loni Mo le ni ipinu nipa nkankan, “Mo gbọdọ ṣe nkan yii,” ki o si di ọla ki nkan ọhun ti jina si mi; ohun miran ti bọ si iwaju mi. Ko si rọrun lati da ara rẹ duro.

8 Ṣugbọn aṣeyọri mi akọkọ ni lati waasu Ihinrere nipasẹ Ijọ, ki n si ṣe gbogbo ohun ti mo le ṣe lati mu ọlá fun Jesu Kristi ni ọjọ yii, bi Mo ṣe wa l'aiye, ni iwọn igba to kun fun mi lati wa l'aiye. Mo ma gbiyanju lati sọ nkan si ọ ti yoo ṣe iranlọwọ fun ọ; ohun kan. Mo kẹkọọ lẹhin ti Mo lọ si ile ni owurọ oni. “Kini Mo le sọ li alẹ yi, Oluwa, ti yoo ṣe iranlọwọ fun awọn eniyan wọnyẹn?”

Mo tẹti si iwasu agbara ti owurọ oni … Ti Arakunrin Neville mu wa fun wa, nipa … Mo ro pe o jẹ iyanu pupọ, bi o ṣe sọ nibẹ, “Dokita yoo ṣe ayẹwo ọran naa; ṣugbọn ọkunrin ti o gbe abọ abẹrẹ dani, ohun ni yoo fun ni ni abẹrẹ.” Ọrọ kekere ti o wuni lori niyẹn. Mo ronu nipa eyi, “omi ara, lẹhin ti a ti wadi ọran naa.” Nitorina iyẹn jẹ ohun ti o dara pupọ.

9 Mo fẹ sọ nkankan fun yin, lati mu yin wa si oye ileri Ọlọrun fun igba yii. Şe o ri? Nkankan, kii ṣe nkan ti ẹnikan miiran wa ni ọjọ miiran, ṣugbọn nkan … ati nigbawo … Awọn nkan yẹn dara; gbogbo wa tọka si awọn nkan wọnyẹn. Ṣugbọn Mo ro pe Emi yoo gbiyanju lati mu nkan wa si ọkan rẹ, pẹlu awọn Iwe Mimọ ti mo kọ si ibi, ti yoo fun o ni òye, yoo si ṣe ọ ni jagunjagun ti o dara julọ ni aaye yii; lati kọ awọn ona àrékérekè ọta, ki o le dènà ohun gbogbo ki o to de ọdọ rẹ. Iyẹn ni ohun akọkọ, lati yàgò fun awon ikunku ni gbogbo òna.

10 Bayi, fun iṣẹju diẹ, ẹ jẹ ki a kiyesi ọjọ nla, ọjọ ẹṣẹ ti a n gbe ni bayi. Èmi ko ro pe ọjọ kan wa ti Mo ti ka ninu itan … Awọn igba inunibini ti o ju eleyi lọ ti wa, nigbati won pa awọn ọmọ Ọlọrun ni ipakupa. Ṣugbọn nipa ẹtan ti ọta, ko si igba kan ti o dabi eyi ti a n gbe ninu rẹ bayi. Igba ẹtan ati àrékérekè ti o julọ ni eleyi. Nigbati mo si rii bẹ, o tu mo si wipe Onigbagbọ ni lati kiyesi ara rẹ loni ju ti tẹlẹ lọ.

11 Bayi, ni aaye igba inunibini ti Rome şe si Ijọ, ti Onigbagbọ ba jẹwo Krístì, wón ma mu lọ si ibi ere idaraya lati fi bó awọn kìnìún, tabi iru ìjìyà bẹ, nítorí ẹri rẹ. Ṣugbọn a gba ẹmi rẹ là, nitoripe o gba Ọlọrun gbọ gidigidi, o si fi ayọ fi ẹjẹ rẹ tán ẹrí rẹ. Bi awọn iṣọn naa ti tu silẹ, tabi awọn iho ninu ara rẹ, ti ẹjẹ si ta jade, yoo pariwo, pẹlu igbagbọ otitọ, o sọ pe, “Gba ẹmi mi, Jesu Oluwa!”

12 Ṣugbọn, nisinsinyi, ọgbọn ète èṣù ni lati jẹ ki awọn eniyan gbagbọ pe awọn jẹ Kristiẹni nigbati wọn si jẹ bẹ. Ohun na niyẹn. O ko ni lati fi ami silẹ … Ẹtan ojo òní ju ti igba inunibini atijó lo. Eṣu ti ṣeto gbogbo idẹkun arekereke ti o le şe … On jẹ ẹlẹtan. Jesu si sọ fun wa, ni Matteu 24, bi ọjọ yii yoo ṣe jẹ ọjọ ẹtan ti o pọ julọ ti o wa laaye, “yoo jọ otitọ débipé yoo tan awọn ayanfẹ Ọlọrun jẹ bi o ba ṣeeṣe fun un.”

13 Nisisiyi ẹ jẹ ki a ṣe afiwe diẹ ninu awọn Iwe Mimọ, tabi awọn asọtẹlẹ ti a sọ ninu Bibeli, fun oni, ki a ṣe afiwe rẹ pẹlu ọjọ ti a n gbe ninu rẹ bayi.

Ninu Timoteu Keji ori keta, a kọ eyi, pe wolii naa sọ pe, “Yoo ṣẹlẹ ni awọn ọjọ yii, pe awọn eniyan yoo jẹ alagidi, ọlọkàn giga, olufẹ fãji jù olufẹ Ọlọrun lọ.” Ṣe afiwe iyẹn ni bayi, fun iṣẹju diẹ. A kii yoo … A o kan só ni ṣoki, nitori a kò ni akókò pupọ lati wo gbogbo rẹ bii o şe yẹ ki a şe; ṣugbọn lati saami si, ki o le rii nigbati o ba de ile ki o kẹkọọ rẹ. “Alagidi, ọlọkàn giga, olufẹ fãji jù olufẹ Ọlọrun lọ; alaile darijini, abanijẹ́, alaile-kó-ra-wọnnijanu, ati alainifẹ-ohun-rere.” “ṢUGBỌN Ẹmí ntẹnumọ ọ pe awọn nkan yi yoo şẹlẹ ni igba ikẹhin.” Iyẹn ni awọn ọjọ wọnyi, ati sọ tẹlẹ.

14 Bayi a tun ka ninu Ifihan 3:14, igba Ijọ Laodicea, nipa bi ijọ yoo ṣe ri ni ọjọ ikẹhin yii. O sọ pe, “Yoo joko bi opó ati pe ko si şe aini ohunkohun. O jẹ ọlọrọ, o si pọ si ninu ẹrù, ko si mọ pe wọn jẹ talaka, alaini, eni oşi, afọju, ati eni ihoho, ko si mọ.” Awọn … Nisisiyi, ranti, O n ba ijo ti asiko yii sọrọ, “ẹni oşi, afọju, onihoho, ko si mọ.” Gbolohun ti o kẹhin yẹn, Ọrọ ikẹhin yẹn, ni ohun ti o jẹ ki o nilo itẹnumó. Wọn ro pe wọn kun fun Ẹmi daradara, gbogbo wọn ti ṣetan. Igba Ijọ ti Laodicea naa ni igba Ijọ Pentikọstal, 'nitori o jẹ igba ijọ ikẹhin. Luther ni iṣẹ iranṣẹ rẹ; Wesley ni iṣẹ iranṣẹ rẹ; Pentikọst na ni iṣẹ iranṣẹ wọn.

15 Pẹlupẹlu, O sọ pe, “Nitoriti iwọ ṣe ìlọ́wọwọ, ti o kò si gbóna, bẹni o kò tutù,” awọn ẹdun ti ita, ero ara nipa Ihinrere; “Nitori,” O sọ pe, “iwọ ri be yẹn, emi o pọ̀ ọ jade kuro li ẹnu mi.” Ni ọrọ miiran, O Olorun lati ri ijọ ninu ipo yẹn.

16 Ranti, wọn le Olorun jade; ati pe O wa ni ita ti ile ijọ, O n gbiyanju lati pada si inu ijo, ni igba Ìjọ Laodicea ti o buruju yẹn.

17 ọlọrun ti ayé yii loni, eni ti gbogbo ayé yii n sin loni, ni Satani. Ati pe awọn eniyan ko mọ pe Satani ni awon nsin, ṣugbọn Satani ni o gbe awọ ijo wọ. Wọn n sin Satani, ni ero pe wọn n sin Ọlọrun nipasẹ ijọ, ṣugbọn ọna ti Satani lo niyẹn.

O le sọ pe, "ni suru; awa naa nwasu Ọrọ naa."

Kiyesi kókó ọrọ mi ni alẹ yi. Satani ni o kọkọ waasu Ọrọ naa fun Efa, "Nje Ọlọrun sọ," wo.

Siṣi oye abala Iwe-mimọ to sọ nipa ọjọ naa. Oun yoo jẹ ki o mọ pe gbogbo ohun ti Jesu ṣe, daradara ni. Oun yoo jẹ ki o mọ pe gbogbo ohun ti Mose ṣe, daradara ni. Ṣugbọn nigbati o ba mu awọn ileri ti o wa fun ọjọ oni, yoo so pe igba miiran niyẹn wa fun. Gbogbo ohun ti o ni lati ṣe niyẹn, kiyesi, ki awọn eniyan gbagbọ pe bẹẹni. Nitori, "Iwọ ko le mu Ọrọ kan kuro ninu rẹ, tabi fi ọrọ kan kun un." Ṣugbọn ohun ti o ma n ṣe iyẹn.

18 Eniyan n sin Satani laimọ, ni ero pe awọn n sin Ọlọrun; gẹgẹ bi a ti kilọ fun wa nipasẹ asọtẹlẹ, ni Tessalonika Keji. E jẹ ki a kan ka iyẹn, Tẹsalóníkà Keji, ori keji. E jẹ ki a kan de bẹ ni kiakia, ti Mo ba le se, lẹsẹkẹsẹ. Emi yoo fẹ lati ka iyẹn. Mo gbagbọ pe Tẹsalóníkà Keji naa ni. Mo ni Iwe-mimọ na nihin. Ni Keji …

*ṢUGBỌN awa mbẹ̀ nyin, ará, nitori ti wíwa Jesu Kristi Oluwa wa, ati ti ipejọ wa sọdọ rẹ̀,*

Nisisiyi, wo, "wiwa Oluwa, ati ikojọpọ si ọdọ Rẹ," bi Ọlọrun yoo ṣe ko awọn eniyan Rẹ jọ sọdọ Rẹ ni awọn ọjọ ikẹhin. "Ikojọpọ awọn eniyan si Oluwa", kii ṣe si ile ijọsin, "si Oluwa; apejọ pọ si ọdọ Rẹ."

*Ki ọkàn nyin ki o máṣe tete mì, tabi ki ẹ máṣe jaiya, yala nipa ẹmí, tabi nipa ọ̀rọ, tabi nipa iwe bi lati ọdọ wa wá, bi ẹnipe ọjọ Oluwa de.*

*Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni tàn nyin jẹ lọnakọna; nitoripe ọjọ na ki yio de, bikoṣepe ìyapa nì ba kọ́ de, ki a si fi ẹni ẹ̀ṣẹ nì hàn* (ẹni ẹ̀ṣẹ, kiyesi re bayi), *ti iṣe ọmọ ègbé,* (Judasi ni yen, kiyesi);

*Ẹniti nṣòdì, ti o si ngbé ara rẹ̀ ga si gbogbo ohun ti a npè li Ọlọrun, tabi ti a nsin; tobẹ ti o joko ni tẹmpili Ọlọrun, ti o nfi ara rẹ̀ hàn pe Ọlọrun li on.*

19 Ẹtan ijọ yẹn li ode oni! Wo, "ọmọ ègbé," eṣu. "Ọmọ ègbé," eṣu. Lẹhinna, awọn eniyan n sin Satani ni oni, ni ero pe awọn n sin Ọlọrun. Ṣugbọn wọn n sin Satani nipasẹ ẹkọ kan, awọn ẹsin ti eniyan ṣe ati awọn ẹkọ ti o mu awọn eniyan wọ ẹtan nla ti o ju ti atẹyin wa lọ. Bi o ti wu ki a waasu Ọrọ Ọlọrun ati awon ileri fun ọjọ yii, wọn ko ni gbagbọ. Won o ni gba gbo.

Kilo faa? O ya wa lẹnu. Kilode ti won ko le gba A gbo? Nigbati Ọlọrun sọ pe Oun yoo ṣe ohun kan, O si ṣe, sibẹ wọn kọ ẹhin wọn si i. Gẹgẹ bi Efa ti mọ pe ohun ti Ọlọrun sọ, Ọlọrun yoo ṣe; ṣugbọn o kọ ẹhin rẹ si i, lati tẹtisi ohun ti o ni lati sọ.

Jọwọ ranti, ni awọn igba to koja, o jẹ ohun kanna nigbagbogbo. Ni gbogbo igba, Satani ma n gbiyanju lati yi Ọrọ naa pada si wọn, ki wọn le şi loye rẹ fun ọjọ miiran.

20 Wo, nigbati Jesu de, kiyesi, Satani wa ninu ẹgbẹ awọn olukọni Juu, ati awọn rabbi ati awọn alufaa, to n gbiyanju lati sọ fun wọn pe ki wọn pa ofin Mose mọ, nigbati Ọrọ gan-an sọ pe ni ọjọ yẹn ni Ọmọ eniyan yoo fi ara han, kiyesi, pe Oun yoo fi ara Rẹ han. Nitorina wọn gbiyanju, niwọn igbati wọn ti pa wọn mọ nipa ẹsin, ati lori ofin Mose. Ṣe ẹ ri ohun ti o ṣe? O n gbiyanju lati sọ fun wọn pe, "Apa Ọrọ naa jẹ ootó, ṣugbọn Ọkunrin yii kii ṣe Ẹni naa." Wo bi o ṣe n tan eniyan jẹ? Iyẹn gangan ni igba ẹtan.

21 O ti wa bẹ tẹlẹ, ati ni bayi, Satani fi idi ijọba rẹ mulẹ ninu ayé. Ìdí ti o fi n ṣe niyẹn, nitori o fẹ fi idi ijọba tirẹ mulẹ.

Gẹgẹbi onişowo ti kii ṣe Onigbagbọ, yoo ṣẹ gbogbo ero ti o le ṣe lati jẹ ki o rii nkan ti ko tọ. Ti o ba ni ete kan ati ere to fẹ gba ninu ki o je ko şe be yẹn, ki o jẹ ki o şi loye ni ọna yen, oun yoo fi ohun gbogbo ti o le ṣe han ọ, yoo si pa ọ mọ kuro ninu otitọ rẹ, nitori ti ara rẹ nikan lo kan-an. Gbogbo irọ ati iyanijẹ rẹ́, ati iyokun, o ni ere ti ara ẹ nibẹ́.

22 Idi ti Satani fi ṣe eyi niyẹn. O si ti şiṣẹ nipasẹ iṣẹ-iranṣẹ lati ṣe, gẹgẹ bi Ọlọrun ti ṣe ileri pe yoo ṣe. Nisisiyi, o bẹrẹ nipasẹ ẹtan ẹsin ni Edeni, o si ti tẹsiwaju lati igba naa.

Kii ṣe nipa siseto akojọpọ awọn komunisiti. Awọn Komunisiti ko ni nkankan ṣe pẹlu eyi. O jẹ ile ijọsin, iyẹn ni ibiti o ni lati wo, wo. Kii ṣe awọn komunisiti ni yoo tan awọn Ayanfẹ gan. Ile ijọsin ni yoo tan awon ayanfe jẹ, kiyesi. Kii ṣe awọn ti komunisti; a mọ pe wọn sẹ Ọlọrun, ati pe wọn ṣodi si Kristi, beẹni, ṣugbọn awọn kii ṣe aṣodisi-Kristi naa. Aṣodisi-Kristi naa jẹ eni ẹsin, o gbagbọ pupọ, o le sọ iwe-mimọ, ki o jẹ ki O yé ènìyàn.

Gẹgẹ bi Satani ti ṣe ni ibẹrẹ, o sọ gbogbo re, "Ọlọrun ti sọ pe,' Iwọ ko gbọdọ jẹ gbogbo igi ọgba naa.'" Kiyesi, yoo sọ O dada.

Obinrin na sọ pe, "Bẹẹni, awa le jẹ ninu gbogbo igi ọgba naa, ṣugbọn igi kan wa laarin ọgba naa ti Ọlọrun sọ pe ki a maṣe jẹ, tàbí fi ọwọ kan; nitoripe, ọjọ ti a ba ṣe, ọjọ naa ni awa yoo ku."

23 O sọ pe, "Ah, dajudaju iwọ kii yoo ku. Ṣugbọn jẹ ki n fun ọ ni idi ti Ọlọrun fi sọ eyi, nitori pe …" Wo, kini o şe bayi? O sọ Otitọ yii, ṣe o rii. O sọ pe, "Yoo ṣii oju rẹ, yoo si jẹ ki o mọ rere ati aṣiṣe. Iwọ yoo dabi Ọlọrun lẹhinna, ti o ba le ṣe."

Iyẹn ni ohun ti o fẹ ṣe, ati pe ohun kanna ni o n gbiyanju lati ṣe loni. Ẹtan ẹsin ti wa lati ibẹrẹ ni Edeni, ati lati igba naa. Ni akoko Adam, o jẹ ẹtan. Ni akoko Noa, o jẹ ẹtan. Ni akoko Jesu, kanna ni. Bakanna ni nisisiyi, ọna kanna, ẹtan nipa ẹsin!

24 Bayi, a ṣe akiyesi ilẹ-aye, nigbati Ọlọrun ti ṣakoso rẹ. Bayi, nigbati o wa labẹ iṣakoso Ọlọrun. Lẹhinna ti Satani gba agbara, nipa kikọ Ọrọ Ọlọrun silẹ. Nigba kan Ọlọrun ni ayé labẹ iṣakoso Rẹ. O ṣeto rẹ. O jẹ ki o ṣiṣẹ. O ṣe ohun gbogbo, o ni ninu iṣakoso Rẹ. Bayi a yoo ṣe afiwe iyẹn pẹlu igbati Satani gba iṣakoso rẹ.

25 Bayi, Ọlọrun lo ẹgbẹrun ọdun mẹfa. Ki şe pe O gbodo pẹ to bẹ, ṣugbọn Olorun fẹ bẹ ni. Ẹgbẹrun mẹfa ọdun, nitori a ti kọ wa pe "ọjọ kan ni Ọrun jẹ ẹgbẹrun ọdun ni aye," ati pe o jẹ ẹgbẹrun mẹfa ọdun, tabi ọjọ mẹfa ti Ọlọrun kọ ilẹ aye. Ni bayii, Ọlọrun lo ẹgbẹrun mẹfa ọdun lati fi idi rẹ mulẹ, gbin awọn irugbin to dara ati lati mu ohun gbogbo jade ni iru tirẹ. Ohun gbogbo gbọdọ jade ti iru rẹ. Gbogbo awọn irugbin Rẹ dara, nitorinaa o gbọdọ mu iru rẹ jade. Ọlọrun lo ẹgbẹrun ọdun mẹfa.

26 Lakotan, nigbati O ti ṣe gbogbo rẹ, awa dé olu ile-iṣẹ aye yi, ni ibi daradara kan ti o wa ni ila-oorun Edeni, ti a pe ni ọgba Edeni. Ọlọrun fi olu-ilu agbaye si ọgba Edeni, ni Egipti, ni opin ila-orun ti ọgba naa.

27 O si fi ọmọkunrin rẹ ati iyawo ọmọ rẹ si iṣakoso lori gbogbo rẹ. Iyẹn tọ. Ohun ti Ọlọrun ṣe niyẹn. O fi wọn si iṣakoso patapata. Wọn le ba awọn afẹfẹ sọrọ, yoo si dẹkun. Wọn yoo ba igi sọrọ, yoo si şídì lati ibi de ibẹ.

Kiniun ati Ikooko jẹun papọ, ati ọdọ-agutan yoo dubulẹ pẹlu wọn. Ko si ibi kankan. O jẹ alaafia pipe, isokan pipe, ohun gbogbo ni pipe, nigbati Ọlọrun ni labẹ iṣakoso Rẹ. Si kiyesi, O ni ... Ohun gbogbo n şişé ninu agbaye Rẹ. Gbogbo ètò nlo. Gbogbo nkan njẹ ewéko; ko si iku, ko si iparun, ko si ìbàjé. Ko si … Pípé ni.

O fi awọn ọmọ ayanfẹ Rẹ, Ọmọkunrin rẹ ati ọmọbirin rẹ, ọkọ ati iyawo, si akoso gbogbo rẹ.

28 O tẹ Ọlọrun lọrun gan! "O si sinmi kuro ninu gbogbo iṣẹ Rẹ, ni ọjọ keje," o si yà ọjọ keje yi si mímó.

Nitori, Ọlọrun wo gbogbo rẹ, lẹhin ti O lo ẹgbẹrun mẹfa ọdun lati to aye yii, lati mu si ipo; ti O si fi awọn oke-nla si ipo, ki o jẹ ki awọn eefin onina gbe awọn oke-nla si oke, ati awọn ohun ti o ṣẹlẹ ni awọn riru ina; mu u gbẹ, o si tun un ṣe ni ọna ti O fẹ. O si jẹ aye ti o lẹwa.

29 Ko si nkankan ti o dabi rẹ, awọn paradise nla ti Ọlọrun! Awon dinosọru nla, ati ohunkohun miiran, ti nrakò nipasẹ rẹ, ati ti awọn ẹranko nla; ko si ipalara ninu wọn. Wọn ṣe jẹjẹ gẹgẹ bi ọmọ ologbo kekere. Wọn ko ni nkankan rara; kò sí àìsàn, kò sí ìbànújẹ́; kò sí kokoro arun kan lori ilẹ. Ah, bi o ti da to!

Awọn ẹiyẹ nla nfò lati igi de igi, Adam si le pe wọn ni orukọ, wọn o si fo sori ejika rẹ ati - wọn o faramọ. Ah, bi ilẹ Ọlọrun yii ti dun to!

30 Lẹhinna O ṣe ọkan ninu awọn ẹda Rẹ lati ara Ara Rẹ. Ọlọrun ni awọn abuda ninu Ara Rẹ.

Bii iwọ ṣe jẹ abuda baba rẹ. Ati pe, o ṣe akiyesi, o wa ninu baba baba baba baba rẹ. Ṣugbọn, ni iyẹn, bi apẹrẹ, ki a sọ bi iru iwọ ati baba rẹ. Bayi, iwọ ko mọ nkankan nigbati o wa ninu baba rẹ. Lati ọdọ akọ ni irugbin ìye ti wa. Ọkunrin ni o ni sẹẹli ẹjẹ; obinrin ni awọn—ẹyin naa; bayi, nitorinaa, sẹẹli ẹjẹ ni iru iye ninu rẹ. Ati pe, lẹhinna, nigbati o wa ninu baba rẹ, iwọ ko mọ nkankan nipa rẹ. Ṣugbọn, sibẹsibẹ, imọ-jinlẹ ati Ọrọ Ọlọrun fihan pe o wa ninu baba rẹ, ṣugbọn iwọ ko mọ nkankan nipa rẹ.

Ṣugbọn lẹhinna baba naa fẹ lati mọ ọ. Nitorina pẹlu iṣọkan baba ati iya, o jade si aye ti baba fi le ri ọ. Bayi, iwọ jẹ abuda baba rẹ. O dabi rẹ, ati pe o ni awọn ẹya ara rẹ ti o dabi ti baba rẹ.

Bayi, bẹẹni Ọlọrun ṣe wa ni ibẹrẹ. Gbogbo ọmọkunrin Ọlọrun ati gbogbo ọmọbinrin Ọlọrun li o wà ninu Ọlọrun li atetekọṣe. Iwọ ko ranti rẹ ni bayi, ṣugbọn o wa nibẹ. O mọ o. O si fẹ ki o wà ki O le kan si ọ, ba ọ sọrọ ati ki o fẹran rẹ, ki o gbọn ọwọ rẹ.

31 Ṣe iwọ ko fẹ ọmọkunrin tirẹ … Ṣe kii ṣe ọjọ nla nigbati ọmọkunrin rẹ le wa si ile ki o joko ni tabili? Nigbati

o ba pada de lati oju-ogun, tabi ohun miiran, ti o ni aleebu; bi iwọ yoo ṣe se ounjẹ alẹ; o pa ọmọ malu ti o sanra, tabi ohunkohun miiran, o si mura silẹ fun u! O jẹ ara ati ẹjẹ tirẹ, o si wa ninu rẹ. Iwọ ko mọ nigbana, ṣugbọn o mọ pe o wa nibẹ.

32 Nitorinaa Ọlọrun mọ pe awa yoo wa nihin, ṣugbọn O fi wa sinu ẹran ki a le kan si wa. Ki O le kan si wa, O di ọkan ninu wa nigbati O di Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun funrararẹ, ekunrẹrẹ ìfihan Ọlọrun. Nitorina iyẹn ni ipinnu Ọlọrun, lati ṣe afihan awọn abuda Rẹ ni idapọ.

Nigbati Mo wa ninu baba mi, Emi ko mọ nkankan nipa rẹ. Ṣugbọn nigbati mo di ọmọkunrin rẹ ti a bi nipasẹ rẹ, Mo jẹ ẹda kan, ara baba mi. Iwọ si jẹ ara baba rẹ.

Ati gẹgẹ bi awọn ọmọ Ọlọrun, awa jẹ ara ẹda Ọlọrun ti o wa ninu Rẹ, a di ẹlẹran-ara bi Oun ti di ẹlẹran-ara, kí a le ni idapọ pẹlu ara wa, gẹgẹ bi idile Ọlọrun lori ilẹ. Iyẹn ni ipinnu Ọlọrun ni ibẹrẹ. Bẹẹni, sa. Iyẹn ni ohun ti Ọlọrun fẹ ni ibẹrẹ.

O ni ohun gbogbo labẹ iṣakoso. O si fi eniyan sinu ọgba Edeni, lori ipinnu ara ẹni; wipe, “Ọmọ, tirẹ ni.”

33 Bi ti o lẹwa to! O tẹ Ọlọrun lọrun to bẹ, ti O fi sinmi kuro ninu gbogbo iṣẹ Rẹ. Gbogbo igi kọ lo mu ẹgun jade. Ko si eso beri lailai ti o jade kuro ninu igi ẹgun. Ohun gbogbo jẹ pipe. Gbogbo awọn irugbin jẹ pipe. Ohun gbogbo wa ni ipo pipe.

Lẹhinna nigbati O lọ lati sinmi diẹ, ọta Rẹ yọ wọle pẹlu ẹtan, o si gba ìṣakoso, nipa iṣitumọ eto Rẹ si awọn ọmọ Rẹ. Nigbawo, O gbẹkẹle ọmọ Rẹ; bi ìwọ na ṣe gbẹkẹle ọmọbinrin rẹ nigbati o ba jade lọ ni alẹ pẹlu ọkunrin kan, nigbati o ba gbẹkẹle ọmọkunrin rẹ nigbati o ni lati jade pẹlu ọmọkunrin ọlọti mimu tabi oni siga. Kiyesi, o gbẹkẹle ọmọ Rẹ, pe oun ki yoo ṣe ohunkohun ti o lodi, ati pe yoo pa gbogbo Ọrọ ti O sọ mọ. Ṣugbọn ọta naa yọ wọlé, bi okunrin arekereke ti yoo ṣi iwa wu nigbati o mu ọmọbinrin rẹ jade; tabi—tabi obinrin kan ti yoo jade lọ pẹlu ọmọ rẹ bakanna. Wo, o yọ wọle. Ọta Ọlọrun yọ wọle o si ṣi Ọrọ naa tumọ fun Efa.

34 Nisisiyi, oun, nipasẹ isubu yii, o ti gba ìṣakoso ọgba Edeni, funrararẹ. O gba a. Ati nisisiyi o ṣe ijọba ẹtan fun ẹgbẹrun ọdun mẹfa; o n tan awọn eniyan jẹ, awọn ọmọ Ọlọrun, bi o ti ṣe nigbana. Nitori wọn ni ipinnu ara ẹni, lati ṣe ohunkohun ti wọn fẹ. Ati ni igbagbọ pe wọn yoo ṣe deede, tabi ni igbẹkẹle pe wọn yoo ṣe deede, sugbon wọn ṣe ohun ti ko tọ, wọn si ta awọn ẹtọ ibi wọn, bi Esau ti ṣe, fun agbaye. Satani si bori rẹ, o si gba a. Ati pe o ti ni ẹgbẹrun ọdun mẹfa lati kọ Edeni tirẹ, bi Ọlọrun ṣe lo ẹgbẹrun ọdun mẹfa lati pari Edeni Rẹ. Ati nipa ẹtan, ẹtan Ọrọ naa, rara, ẹtan awọn eniyan, o fi idi Edeni tirẹ kalẹ ninu aye yii, ninu ẹṣẹ.

35 Edeni Ọlọrun fi idi mulẹ ninu ododo. Edeni ti Satani fi idi mulẹ ninu ẹṣẹ, nitori Satani jẹ ẹṣẹ. Ọlọrun li ododo, a si fi idi ijọba Ọlọrun mulẹ ninu ododo, ati alafia, ati Iye. Ile-iṣẹ Satani wa ninu ẹṣẹ, ati ẹṣẹ ẹsin.

Ṣe akiyesi bi o ti tan, ẹtan rẹ, bi o ti sọ pe yoo ṣe. O ṣe ileri lati ṣe eyi. Ṣe ẹnikẹni mọ eyi? E jẹ ki a ṣi Aísáyà, ti o ba fẹ diẹ ninu awọn Iwe Mimọ wọnyi. Ti o ba … O yẹ ki n sọ diẹ sii ninu wọn, Mo ro bẹ. E jẹ ki a ṣi si Aísáyà ori kẹrinla, ni iṣẹju kan, ki o kan wo ohun ti Satani sọ nihin, iṣẹju kan. Ninu Aísáyà 14, a yoo ka a, ki o si wo ohun ti ẹniyi ṣe. Aísáyà 14, bẹrẹ pẹlu ẹsẹ kejila.

> *Bawo ni o ṣe ṣubu lati ọrun wa, Iwọ Lusiferi, irawọ owurọ! bawo li a ti ṣe ke ọ lu ilẹ, iwọ ti o ṣe awọn orilẹ-ède li apa!*
>
> *Nitori iwọ ti wi li ọkan rẹ pe, Emi o goke lọ si ọrun, emi o gbe itẹ mi ga kọja awọn irawọ* (awọn ọmọ), *awọn irawọ Ọlọrun: emi o si joko pẹlu lori oke ijọ enia ni iha ariwa:*
>
> *Emi o goke kọja giga awọsanma; emi o si dabi Ọga-ogo julọ.*

36 Nisisiyi ṣe afiwe eyi nihin pẹlu iwe-mimọ wa miiran ti o wa ni Tessalonika, ni igba diẹ sẹhin, bi o ti sọ pe, “O joko ni tẹmpili Ọlọrun, o gbe ara rẹ ga ju gbogbo ohun ti a pe ni Ọlọrun, ki a le sin bi Ọlọrun lórí ilẹ̀ ayé.”

Iyẹn ni olori agbaye yii ti Mo waasu fun yin ni ọjọ Sundee ti o kọja. Ohun re loni ninu ẹtan, wakati ẹlẹ̀tan yẹn, akoko nla ti a n gbe. O jẹ akoko ologo julọ ni gbogbo awọn igba ti o ti kọja, nitori a tun dojukọ Ẹgbẹ̀rún Ọdun nla lẹẹkansii; a tun nkọju si Edeni. Ṣugbọn ni deede igba yii, gbogbo ẹtan ati gbogbo ọgbọn ti o ti lo lati ṣẹtan pẹlu, o ko gbogbo rẹ jọ o si mu ara rẹ le; ki o si sọkalẹ bi Ọlọrun, o si ti fi ara rẹ si ipò Ọlọrun; ẹlẹsin, o le sọ Iwe mimọ fun ọ, gẹgẹ bi Satani ṣe si Efa ninu ọgba Edeni. Ṣugbọn yoo fi aaye kan silẹ ninu rẹ, o jẹ gbogbo ohun ti o ni lati ṣe, ṣi alafo yẹn, nibiti ẹkọ majele ti eṣu le ṣan silẹ, bii asẹ eniyan ti nronu ti a n sọrọ ni alẹ ti o kọja.

37 Bayi, o sọ pe oun yoo gbe ara rẹ ga ju Ọga-ogo lọ; oun yoo goke awọsanma ati awọn irawọ, yoo si joko nibẹ bi Ọlọrun, yoo si wa loke Ọga-ogo julọ. Ati pe o ti ṣaṣeyọri ni ṣiṣe awọn irokeke rẹ. Dajudaju o ti ni aṣeyọri iyalẹnu ni ṣiṣe awọn irokeke rẹ, nitoripe awọn eniyan ma n jẹ ki o ṣalaye iye ti Ọrọ ileri Ọlọrun si ọjọ

yẹn ni gbogbo igba. Bi o ti ṣe gangan niyẹn. Ni gbogbo ọjọ, o ṣalaye rẹ kuro.

38 Ni igba Noa, o ṣalaye pe ko ṣee ṣe ki ojo rọ lati ọrun wá, nitori, "ko si ojo kankan nibe." Ihinrere imọ-jinlẹ nla rẹ ti o waasu ninu ọgba Edeni! O le ta awọn ohun-elo si oṣupa ki o fihan pe ko si ọrinrin nibẹ. Ṣugbọn Ọlọrun sọ pe ojo yoo rọ. Ṣugbọn Satani ṣaṣeyọri, o si fi majele si ọkan awọn eniyan, nipasẹ iwadi ijinle sayensi, pe, "ko le ṣẹlẹ." Ṣugbọn o ṣẹlẹ. Ọlọrun sọ pe yoo ṣee ṣe, o si ti ṣẹ. O ṣe.

39 Bayi, ni igba ti—ti Jesu, o ṣe ohun kanna. O tun fi majele si ọkan wọn pẹlu ẹtan, kiyesi, ni ìṣìtumọ Ọrọ naa. "Ti Iwọ ba jẹ Ọmọ Ọlọrun, nisisiyi jẹ ki n rii pe O ṣe nkan nipa rẹ."

Jesu ko ṣe awada fun un. Ko ṣe rara. Ọlọrun kii ṣe alawada. Ko nilo lati dahun ohunkohun ti Satani beere. Oun nikan ni … Jesu sọ pe, "A ti kọ ọ pe,' Iwọ ko gbọdọ yè … Eniyan kii yoo wa laaye nipa akara nikan, ṣugbọn nipa gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade.'" Wo, Ko ni lati ṣe awada pẹlu rẹ. Ko nilo lati ṣe akara. O le ṣe, ṣugbọn Oun yoo ti tẹtisi eṣu, nitorinaa ko ni lati tẹtisi eṣu.

40 Lẹẹkansi o jẹ ẹṣẹ ẹsin, bi ni ibẹrẹ, o le tani jẹ gan-an. Kiyesi bayi. Kii ṣe ẹṣẹ ojoojumọ nikan, ṣiṣe agbere ati mimu ọti, ati lilo Orukọ Ọlọrun ni asan. Kii ṣe iyẹn. Bẹẹkọ.

O ranti awọn ọdun sẹhin, ọpọlọpọ ninu yin nibi, awọn ara atijọ, ranti iwaasu ti mo waasu, lori, *Awọn Ibanujẹ Ni Idajọ.* Alagbere naa, kii yoo ni ibanujẹ nibẹ. O mọ ibiti oun nlọ. ọmuti ki yoo ni ibanujẹ nibẹ. Olọti, olutayo, opuro, ole, ko ni ni ijakulẹ. Ṣugbọn, fun ọkunrin yẹn ti o ro pe oun tọ, ibanujẹ wa.

Iyẹn ni ẹni naa, to sọ pe, "Oluwa, ṣe emi ko waasu Ihinrere, ṣe emi ko tii le awọn ẹmi eṣu jade ni Orukọ Rẹ?

41 Jesu sọ pe, "Kuro lọdọ mi … kuro lọdọ Mi, ẹnyin ti nṣe aiṣedede. Emi ko mọ ọ rara." Ibẹ ni ijakulẹ wa, wo, ẹtan naa.

Iyẹn ni ohun ti awon eniyan fi ma n ṣìmí loye nigbagbogbo … Kii ṣe pe Mo fẹ yatọ. Emi ko fẹ ṣe iyatọ, ṣugbọn Mo ni lati jẹ olootọ. Mo ni Iṣẹ iranṣẹ kan, Iyẹn si gbọdọ de awọn ọdọ eniyan naa. Opọlọpọ awọn eniyan lo ṣii loye. Wọn ro pe Mo tako gbogbo eniyan. Ki wọn mọ pe Mo wa fun gbogbo eniyan, Mo si n gbiyanju lati mu ohun ti o jẹ Otitọ wa fun wọn, gẹgẹ bi a ti fi le ọkan mi ati ọna ti a fi lelẹ ninu Bibeli nibi. Ati pe Ọlọrun fihan pe Otitọ ni, nitorinaa ko si ohun miiran ti o le ṣe nipa rẹ. Nitorina, wọn le wo O, tabi ki wọn ma ṣe.

42 Wo, wọn ko fẹ rii, nitori wọn ti sẹ, won ti ta awọn ẹtọ-ibi wọn fun eto eniyan, ẹyamẹya kan; lati lọ si Ọrun lori ipilẹ eto ẹsin, eyiti Satani jẹ ori gbogbo rẹ. Ọlọrun ko ni eto ẹsin kankan ri. Wọn si gba iyẹn, nibiti wọn, opo eniyan, ṣe itumọ Ọrọ naa sọ pe O tumọ si eyi ati O tumọ si iyẹn.

Ọlọrun ko nilo onitumọ. O n ṣe itumọ ara Rẹ. Ko nilo elomiran lati sọ fun Un bi o ṣe le ṣe. Oun ni aṣeyiohun. O sọ bi Oun yoo ṣe ṣe, bẹẹni O si gbọdọ mu Ọrọ Rẹ ṣẹ. Nigbati O sọ pe, "Awọn ami wọnyi yoo tẹle awọn ti o gbagbọ," Bẹeni yoo ri. Ohunkohun ti O sọ yoo waye, O sọ pe yoo ṣẹlẹ ni awọn ọjọ ikẹhin wọnyi, pe Oun yoo ṣe awọn ohun kan, O si ṣe. Ko ni lati beere lọwọ ẹnikẹni boya o to akoko tabi rara. O mọ ohun ti akoko jẹ, ati oun ti eto naa jẹ.

43 Nisisiyi, Satani, ẹlẹtan yii, bi a ti sọ ninu Matteu 24:24, pẹlu ẹtan pupọ. Nisisiyi, a rii pe nipasẹ awọn eto ihinrere rẹ ti imọ, ẹkọ ti o dara julọ, ilana rere ti o ga julọ, ọlaju, ati bẹbẹ lọ, ti tan awọn eniyan ti o fẹ lati sin Ọlọrun jẹ, lati gba irọ rẹ gbọ.

Efa ko fẹ ṣe bẹ, ṣugbọn o fihan-an bi o ti jẹ ọna imọ sii. Efa ko mọ, o si fẹ mọ. Ko ye, ṣugbọn o fẹ ni oye rẹ. Ọlọrun si ti sọ fun u pe ki o ma gbiyanju lati loye.

Bawo ni Mo ṣe le loye eyikeyi ninu nkan wọnyi? Emi ko le loye wọn. Mo gba won gbo. Emi ko ni lati loye wọn. Ọlọrun ni igbagbọ, kii ṣe oye. A kan gba ohun ti O wi gbo.

44 Nisisiyi, ṣe afiwe Edeni Ọlọrun ati ti Satani nisinsinyi, lẹhin ẹgbẹrun ọdun mẹfa ti o fi yi itumọ otitọ Ọrọ ileri ti Ọlọrun ṣe fun igba naa. Jẹ ki a ṣe afiwe rẹ bayi, ki a wo ibiti a ba de. Gẹgẹ bi o ti ṣe si ile ijọsin ni—ni akoko Kristi, nigba Jesu, to n gbiyanju lati dari awọn ọmọ oloootọ Ọlọrun kuro nibi Otitọ naa. Iyẹn ni ti Ọlọrun. Ọlọrun fi awọn ọmọ Rẹ sihin, awọn abuda Rẹ, lati ni idapọ pẹlu Rẹ nipa gbigbo Ọrọ Rẹ.

45 Boya ti baba rẹ ba sọ fun ọ, bi iwọ ṣe jẹ ọmọ oloootọ si baba rẹ, o si sọ fun ọ pe, "Ọmọ, maṣe lọ wẹ ninu odo yẹn, odo, nitori awọn ẹranko bi ooni wa ninu odo yẹn"; eniyan miiran si wa, o sọ pe, "Dajudaju, iru odo ti o lẹwa bii iyẹn, ko si' awọn ẹranko bi ooni ninu rẹ'? Bayi tani iwọ yoo tẹtisi si? Ti o ba jẹ ọmọkunrin tootọ, iwọ yoo tẹtisi baba rẹ.

Bẹẹni ọmọkunrin tabi ọmọbinrin tootọ ti Ọlọrun yoo gba Ọrọ Ọlọrun ni akọkọ. Emi ko fiyesi ohun ti

ẹnikẹni miiran sọ nipa rẹ, wọn gba Ọrọ Ọlọrun ni akọkọ. “Majele mbẹ ninu ago,” wọn si gbagbọ.

Nipa igbagbọ ninu gbogbo Ọrọ Rẹ, awọn Irugbin Rẹ mu Edẹni iwa mimọ, ifẹ, ati iye ainipẹkun wa. Iyẹn ni Edeni Ọlọrun ṣe, iwa mimọ. O si mu Edeni ti iwa-mimọ, ti ifẹ, oye, pipe, ati iye ainipẹkun. Iyẹn ni ohun ti Ọlọrun ngbin, Ọrọ Rẹ, Iru-ọmọ Rẹ. Iyẹn ni ohun ti Ile-ijọsin Rẹ yoo jẹ ni ikẹhin; Yoo jẹ ohun kanna.

46 Kiyesi, ero kan ni eyi. Maṣe gbagbe rẹ. Emi yoo sọ nipa rẹ ni akoko miiran tabi Iwaasu miiran. Ṣugbọn, o mọ, Ọlọrun sọ pe, “Jẹ ki gbogbo irugbin mu iru tirẹ jade.” Njẹ aṣẹ Ọlọrun niyẹn? Nisisiyi oniwaasu tabi ẹnikẹni miiran wo lo gbọdọ gbiyanju lati jẹ ki Ọrọ yẹn sọ nkan miiran? Kiyesi, gbogbo Ọrọ Ọlọrun ni Irugbin. Jesu sọ bẹẹ, “afunrugbin kan funrugbin.” Nitorina ti Marku 16 ba jẹ Ọrọ Ọlọrun, yoo mu iru rẹ wa. Ti Malaki 4 ba jẹ Ọrọ Ọlọrun, yoo mu iru rẹ wa. Ati pe gbogbo ileri miiran gbọdọ mu iru rẹ jade.

47 Ṣe o rii bi Satani ṣe iparada nihin? O n gbiyanju lati sọ pe, “Kii ṣe, kii ṣe bẹ.” Ṣe o ye o? [Ijọ sọ pe, “Amin.” — Ed.] Wo, Satani sọ pe, “ah, Iyẹn kii ṣe fun oni. Iyẹn, iyẹn—iyẹn … Iyẹn jẹ akoko miiran. Iyẹn, iyẹn paapaa ko tumọ si iyẹn.”

“Gbogbo irugbin gbọdọ mu iru tirẹ jade.” Iyẹn ni bi Ọlọrun ṣe fi idi Edeni Rẹ mulẹ. Njẹ iyẹn tọ? [Ijọ sọ pe, “Amin.” — Ed.] Bayi ni, bẹẹni Ọlọrun ṣe fi idi Ijọ Rẹ mulẹ, gbogbo Ọrọ lẹhin iru Rẹ! “Eniyan kii yoo wa laaye nipa akara nikan, ṣugbọn nipa gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade.” Se ẹ ri? Satani, yoo gba nkan miiran. Ṣugbọn Ọlọrun sọ pe, “Gbogbo irugbin ni iru tirẹ.”

Ti ileri naa ba sọ pe, “Awọn ami wọnyi yoo tẹle awọn ti o gbagbọ.”

Ni bayii ijọ ẹyamẹya naa sọ pe, “Darapọ mọ ijọ. Tun ẹkọ naa sọ. Mọ katakisi naa.” Ko si iru nkan bẹ ninu gbogbo Bibeli.

Ṣugbọn Jesu sọ pe, “Awọn ami wọnyi yoo tẹle awọn ti o gbagbọ: ni Orukọ mi wọn yoo le awọn ẹmi eṣu jade; wọn yoo sọrọ pẹlu awọn ede titun; ti wọn ba mu awọn ejò, tabi mu awọn nkan apaniyan, kii yoo pa wọn lara; bí wọn bá gbé ọwọ́ wọn lé aláìsàn, ara wọn yóò yá.” Ta lo le sọ pe Ko ri bẹ? Se ẹ ri?

48 “Gbogbo irugbin yoo mu iru tirẹ wa.” Ti o ba jẹ iru-ọmọ Ọlọrun, abuda, ọmọ Ọlọrun, irugbin Ọrọ Ọlọrun wa ninu rẹ niyẹn. Se ẹ ri? Nigbati o ba si gbọ Ọrọ Ọlọrun, “Awọn agutan mi ngbọ Ohun Mi; wọn kii yoo tẹle alejò.” Se o ye yin? “Gbogbo irugbin yoo si mu iru tirẹ jade.”

49 Bayi, a rii pe gbogbo irugbin ti o mu iru tirẹ jade, ko si iku ninu titun … ni Edeni yẹn. Ko ni si iku ninu Edeni tuntun. Kiyesi, ko si ohun miiran bikoṣe iwa mimọ, mimọ, ati iye ainipẹkun.

Nisisiyi, aigbagbọ ninu gbogbo Ọrọ Ọlọrun lo mu irugbin ti aimọ ni Edeni Satani. Nisinsinyi a ti n wọle sibiti Satani ngba itẹ, bi Aṣodisi-Kristi, ninu—Eden ti ilẹ yii, Edeni ti ẹṣẹ, ẹsin ti o ti bajẹ. Oun ko bẹrẹ, “Emi ni Satani. Emi ni angẹli nla naa.” Rara, kii ṣe lori iyẹn, ṣugbọn lori yiyi Ọrọ Ọlọrun pada. Iyẹn ni bi o ṣe mu ijọba rẹ wa, ni gbogbo igba. Ati nisisiyi ni ọjọ ẹtan nla yii, ti o n mura lati gba itẹ rẹ, nipasẹ awọn eniyan rẹ! O ti kọ Edẹni ti imọ, ti ò n kàwe, ti imọ-jinlẹ fun ara rẹ; nitootọ, awọn oniwaasu onimọ-jinlẹ, ile ijọsin onimọ-jinlẹ, ẹkọ nipa imọ-jinlẹ, gbogbo nkan jẹ imọ-jinlẹ. Ohun gbogbo wa lori ipilẹ ti imọ. Gbogbo ijo ni a gbe kale lori imo. A ko kọ lori igbagbọ.

50 Nigba kan mo lọ ṣe ipade ni ile ijọsin ọkunrin kan. O jẹ gbongan nla ni iwọ-oorun. Eniyan ti o dara, ko si gba awọn nkan ti a n sọ wọnyi. Ṣugbọn sibẹsibẹ, o jẹ … Mo fẹran rẹ; eniyan dada, baba agba. Nigbati ijọ rẹ jade … Ijọ rẹ gba ẹgbẹrun mẹfa eniyan. Nigbati awọn ọmọ ijọ rẹ jade, ni isin ọsan, wọn to ẹgbẹrun kan at'abọ, gbogbo wọn jẹ awọn amoye ti o wọ aṣọ daradara. Mo joko nibe ti mo n wo won.

Iwaasu ọkunrin naa dara pupọ. Lẹhinna o beere boya ẹnikẹni fẹ gba Kristi, ki o na ọwọ wọn soke. Ko si enikan ti o gbe owo won soke. Nipari obinrin kan wa gbe ọwọ rẹ soke. O sọ pe, “O dara, bayi o ti di Onigbagbọ,” o si ṣe iribomi fun. Ati lẹhinna nigbati o jade lọ … O ya ọmọ kan si, o fi ẹnu ko ọmọ kekere naa o si gba adura lori rẹ, o si bukun fun awọn ọmọ ijọ nipari.

51 Nigbati awọn ọmọ ijọ rẹ jade; gbogbo wọn jẹ ọmọwe, awọn eniyan to dun wo. Lẹhinna Mo duro ni ẹgbẹ kan lati gbọn ọwọ oniwaasu naa, lati dágbére fún un, bi o ti n jade.

Nigbati mo ti ṣe bẹ, lẹhinna ni awọn eniyan ti o fẹ gbọ iwaasu temi wọle de. Wọn ko jẹ ki wọn wọle nigba ti awọn ọmọ ijọ tirẹ wa nibẹ. Bi awọn eniyan temi ṣe de niyi, ninu awọn kẹkẹ abirun, awọn atẹsẹ, ninu aṣọ ati jaketi ti o nira, awọn asiwere, ati ohun gbogbo miiran. Wo iyatọ? Bẹẹni. Ohun ti Mo n sọ niyẹn, wo. Wo, o jẹ nkan ti o yatọ.

52 Nipa imọ-jinlẹ, o le waasu Ihinrere oye, pe, “ẹni ti o ba gba Jesu Kristi gbọ ni a ko le da lẹbi,” wo.

Ṣugbọn, “Awọn ami wọnyi yoo tẹle awọn ti o gbagbọ,” kiyesui, o kuna lati fi Iyẹn naa si, wo. O gba Jesu

Kristi gbọ, o ti fipamọ, ti awọn ami wọnyi ba tẹle onigbagbọ.

“Ati ẹniti o gbọ Ọrọ mi,” kii ṣe pe o kan ṣe, ko gbọ pẹlu etí rẹ nikan, ṣugbọn, “loye rẹ.” Ẹnikẹni le gbọ Ọrọ; aṣẹwo le gbọ Ọrọ ki o ṣi jẹ aṣẹwo sibẹ; wo, ọmuti le gbọ Ọrọ; opuro le gbo O ki o si jẹ opurọ sibẹ. Ṣugbọn, “Ẹniti o loye Ọrọ mi, ti o si gba Ẹni ti o ran mi gbọ, o ni Iye ainipẹkun.” Bo ṣe ri niyẹn, wo.

Ati pe ko si eniyan ti o le ṣe iyẹn ayafi ti Ọlọrun ba ti pinnu rẹ tẹlẹ. Jesu sọ pe, “Ko si eniyan ti o le wa sọdọ mi, ayafi ti Baba mi ba fà a, ati pe gbogbo ẹni ti Baba ti fifun mi yoo wa sọdọ mi.” Amin. O jẹ aṣẹ-ọba ati imọ-tẹlẹ ti Ọlọrun. Oun lo dawa ati pe ko si ẹnikan ti o sọ ohun ti o le ṣe fun Un.

53 Nisinsinyi, nipa aigbagbọ, nipa kikọ abala Ọrọ Ọlọrun silẹ, o ti mu ki irugbin ti aigbagbọ, aimọ, ẹṣẹ, ikorira, ati Iku Ainipẹkun wa ni igba ẹlẹṣẹ ati imọ aye yii. So ye yin bi? Ni ọjọ yii, nigba ti gbogbo agbaye jẹ ẹlẹsin! Njẹ o mọ bẹ? Gbogbo agbaye jẹ ẹlẹsin. Ni igba ẹsin yii pẹlu, ti awọn ijọ nla wà ni gbogbo ihà; gbogbo nkan, gbogbo nkan pari sinu ijọsin Satani. Ohun nìyí, ninu Bibeli. Iyẹn tọ. Awọn seminari ọjọgbọn yii ti kọ eniyan ni òye, bi a ṣe nsọrọ, bi a ṣe n huwa, bi o ṣe le dari imọlara wọn; wọn ma n lo ọdun mẹta si mẹrin lati kọ ẹkọ ọrọ inu ọkan. Wo, o jẹ …

Ẹmi Ọlọrun kii ṣe nkan ti a ma n kọ eniyan. O jẹ nkan ti a ti pinnu tẹlẹ sinu rẹ, nipasẹ ọwọ Ọlọrun Olodumare. Awọn ẹkọ ile-ẹkọ rẹ ko le fun ọ ni iriri. A ti pinnu ẹ tẹlẹ, nipasẹ ọwọ Ọlọrun ati imọ-tẹlẹ Ọlọrun, sinu rẹ. Iyẹn tọ.

54 Nisisiyi, o mu Edẹni nla yii ti wọn n gbe bayi wa, Edẹni ti ijọ agbaye. Gbogbo wọn parapọ bayi ni Igbimọ ẹyamẹya nla ni, wọn a si ko gbogbo ijọ agbaye papọ sabẹ adari kan, nibiti ao ti fi Satani si itẹ, bẹẹni.

Ipe ikẹhin si n jade, lati mu Iyawo ṣaaju ki O to wọ inu iyẹn. Nitori ti O ba wọ inu igbimọ yẹn, o ti gba ami ẹranko naa, o si ti ṣ'egbe, ko ni jade ninu rẹ. Iyẹn ni idi ti o fi sọ pe, “Ẹ jade kuro laarin wọn, Eniyan mi,” ki o to lọ sinu rẹ, wo. “Ẹ jade kuro lãrin wọn, ki ẹ si yapa.”

55 Nisinsinyi, ikorira ati iku, ati ipinya ayeraye kuro lọdọ Ọlọrun, ninu Edẹni yii; ifẹkufẹ, idọti, ibajẹ, (bawo?) nipa gbigbin irugbin odi.

O ran mi leti iran ti Mo rii ki n to pade awọn eniyan Pẹntikọsti, ti Ọkunrin naa n lọ kakiri aye, pẹlu ẹwu funfun. Mo ti sọ fun yin ni ọpọlọpọ igba. Ẹnikan si wọle lẹhin Rẹ, o funrugbin awọn irukerudo.

O gba ẹtọ yẹn nitootọ, ni Efa… ninu ọgba Edẹni, nipa ifẹkufẹ Efa fun ẹṣẹ; ifẹkufẹ fun Efa, ti ẹṣẹ. Lẹhinna, ti Efa ba n fẹ imọ aye, ẹṣẹ ni.

Nigba ti awa naa ba ni ifẹkufẹ fun imọ aye, fẹ Ph.D., LL.D., o jẹ ẹṣẹ lati ṣe bẹ. Ọrọ to lagbara niyẹn, ṣugbọn Otitọ ni. Ko si bi o ti lagbara to, o ṣi jẹ Otitọ, wo. Lati ṣe ifẹkufẹ fun imọ aye, oye!

Ohun ti o n ṣẹlẹ loni nipe a ko gbiyanju lati fi idi Ọrọ Ọlọrun mulẹ ninu ọkan awọn eniyan. A n gbiyanju lati fi idi ara wa mulẹ. Awọn ile ijọsin n gbiyanju lati fi idi ẹkọ ti ile ijọsin mulẹ, ni ọkan eniyan.

A paṣẹ fun wa lati fi idi Ọrọ Ọlọrun mulẹ. Paulu sọ pe, “Emi ko wa sọdọ yin pẹlu ọrọ iyanju ti eniyan, ki igbagbọ yin le duro ninu imọ eniyan; ṣugbọn emi tọ ọ wá ninu agbara; ninu awọn ifihan ti Ẹmi Mimọ, ki igbagbọ rẹ le sinmi le Ọlọrun.” Bo ṣe ri niyẹn.

56 Eniyan ko gbọdọ gbe ara rẹ ga. A ri laarin … Ti Ọlọrun ba ṣe ohunkan fun eniyan pẹlu iṣẹranṣẹ, gbogbo ẹni ìyoku ma n gbiyanju lati ṣe ifarahan irọ rẹ. Wo, wọn n gbiyanju lati gbe ara wọn ga. Gbogbo eniyan, “Mo ṣe eyi. Emi, Emi, temi, ijọsin mi, emi, eyi, ”n fi idi ara wọn mulẹ. Kini a n waasu nipa rẹ, funrararẹ tabi Ijọba Ọlọrun?

Ẹ fi idi Ọrọ Ọlọrun mulẹ. Mu aigbagbọ jade ki o si fi idi ijọba Ọlọrun mulẹ ni ọkan eniyan. Ati pe ijọba Ọlọrun ko le fi idi mulẹ ni ọkan eniyan afi ti Ọlọrun ba ṣe bẹ. Ko le fi idi mulẹ ni …

Ati pe, ranti, apakan ẹtan, ti awọn eniyan ro pe o tọ. Kiyesi. “Ọna kan wa ti o dabi ẹnipe o tọ si eniyan.” Gbogbo eniyan ti o ni oye dabi ẹni pe o tọ.

57 Gẹgẹ bi Mo ti sọ fun yin ni ọjọ Sundee diẹ sẹhin; nigbati mo duro ti ọmọ mi ti n ku, ati pe Satani duro nibẹ o sọ pe, “Baba rẹ niyẹn, o ku ni ọwọ rẹ ni alẹ to kọja. Iyawo rẹ ti wa ninu ibojì, ọmọ rẹ lo si n ku lọ yi. O si gbadura sí Ọlọrun, O si fa ... O fi iboji dudu sori adura rẹ. Sibẹsibẹ Oun ni Ọlọrun ti o dara, ati pe sibẹsibẹ o sọ pe O jẹ Oniṣegun nla. Iwọ ree, ti o duro lori ohun ti o tọ, o ṣe aṣiṣe.” Ah, gbogbo idi, gbogbo ero ọkan mi gba pe o tọ, ati pe o ootọ lo sọ, de ibẹ yẹn.

Bẹẹ ni o tọ nigba ti o sọ fun Efa pe, “Oju rẹ yoo la, iwọ o si mọ ododo ati buburu. Ati pe iwọ yoo dabi awọn òrìṣà, ni ọna yẹn, ti o mọ ododo ati aṣiṣe, ”nitori Ọlọrun ko ti jẹ ki wọn ri ara wọn, pe wọn wa ni ihoho.

Nitorinaa wọn mọ pe wọn yoo mọ eyi ti o tọ si buburu; o si tọ. Ṣugbọn, ṣe o rii, o tako Ọrọ Ọlọrun.

58 Bẹẹ ni awọn minisita ninu awọn ile-ẹkọ giga, nkọ ẹkọ nipa ẹkọ ti eniyan ṣe; o le dabi pe o tọ, o le jẹ oye ti o dara fun nkan naa, ṣugbọn àṣìṣe ni.

A ko ni lati l'oye Rẹ. A gbagbọ nitori Ọlọrun sọ pe o ri bẹ, iyẹn si yanju rẹ lailai. Iyẹn ni ọna lati gba gbogbo Rẹ gbọ.

Ah, bi Efa ṣe fẹ lati ni Ph.D., wo, bi o ṣe fẹ lati gbọn ju ohun ti o jẹ lọ!

59 Ṣe akiyesi bakanna, ọkunrin ati iyawo rẹ … Bayi ṣe akiyesi, ọkunrin ati iyawo, mejeeji ni ihoho ninu ọgba Edeni, Edeni Ọlọrun.

Bayi Emi yoo m'ẹnu duro. Mo sọ pe Emi yoo kan lo iṣẹju diẹ. Wò, wo nisisiyi, ni ipari.

Ṣe afiwe eyi bayi, bi ọkunrin yẹn ati iyawo rẹ ṣe ri, ni Edeni Ọlọrun, laisi aranpo aṣọ kan lori wọn, ti wọn ko mọ. Kilode ti wọn ko mọ? Nipasẹ Iboju Mimọ, ti Ẹmi Mimọ ni wọn ko fi ni imọ ihoho. Wọn le wo ara wọn, wọn ko si mọ pe awọn wa ni ihoho. Won wa ni abẹ àbò Emi Mimọ, ti iwa mimọ. A bo wọn loju.

60 Iboju Ọlọrun, sibẹ loni, le rí ki o si ma ṣe ifẹkufẹ. Wọn a kọ orí wọn si ibomiran. O jẹ Iboju Mimọ, wo, Iboju Mimọ. Ọlọrun ni oju wọn … awọn mejeeji, ọkan jẹ ọkunrin ekeji si jẹ obinrin, wọn ko mọ pe wọn wa ni ihoho, nitori iwa mimọ ti Ọlọrun pa oju wọn mọ. Akiyesi, Ọlọrun fi ẹri-ọkan wọn pamọ kuro ninu ẹṣẹ, nipasẹ Iboju Mimọ.

Akoko o to sọrọ diẹ si lori iyẹn, iṣẹju diẹ. Wo ibi, “Nitoriti oun, olujọsin ti a wẹ lẹẹkan,” Iwe awọn Heberu, “olujọsin ti a wẹ lẹẹkan, ko ni ifẹ ti ẹṣẹ mọ.” Ẹṣẹ ti kọja kuro lọdọ rẹ.

61 Mo gbọ ti Arakunrin Neville sọ ni owurọ yii; ẹnikan le ti beere lọwọ rẹ idi ti emi ko fi waasu lori Ẹmi Mimọ, kilode ti emi ko ṣe eyi. Eyi ni. Ẹmi Mimọ ni iṣe inu rẹ. Igbesi aye ni, kii ṣe imolara; kii ṣe ẹri ti ara. Ṣugbọn O jẹ Eniyan kan, Jesu Kristi, Ọrọ Ọlọrun ti a fi idi mulẹ ni ọkan rẹ, lati sọ gbogbo Ọrọ igba yii di ààye. Ọ tọ. Ṣọ bi Ẹmi Mimọ ṣe nṣiṣẹ, kii ṣe itage; ṣugbọn iṣe ni, iṣẹ to ba Ọrọ naa mu.

62 Ṣe akiyesi Ẹmi Mimọ bayi, ti Ọrọ Mimọ Ọlọrun, ọkunrin ati obinrin wa ni ihoho, wọn ko si mọ. Bi o ti lẹwa to, Igbesi aye Oro naa; irugbin, Ọrọ naa!

Ọlọrun sọ pe, “Igi kan wà lãrin ọgbà naa, obinrin naa. Ni arin ọgba naa ni igi yi wa; maṣe fi ọwọ kan. Nitori, ọjọ ti iwọ ba jẹ ninu rẹ, ọjọ na ni iwọ o ku.” Wọn wa ni abẹ àbò mimọ, wọn kò mọ nkankan nipa rẹ, wọn kò ni igboya lati fi ọwọ kan.

Wọn wa ni abẹ àbò mimọ. Wọn wa lailewu ninu agọ Ọlọrun. Wọn wa laaye. Wọn ko ni iku ni ayika wọn. Halleluyah! Wọn ni ifẹ pipe ọkan fun ekeji, Iye pipe lailai. Wọn ni ifẹ pipe, oye pipe ti ifẹ Ọlọrun. Wọn ni Ọrọ Ọlọrun, wọn si pa a mọ. Ati pe wọn wa laaye ati ailewu ni Edeni Ọlọrun, laisi iku, rara, ni ayika.

63 Lẹhinna, Satani fa ki Efa tẹtisi ihinrere ti ẹkọ ẹsin rẹ, ihinrere ti imọ, ile-iwe giga, ẹkọ ihuwasi ti o ga julọ, ọlaju ti o dara julọ, ẹkọ giga, ati bẹbẹ lọ; lẹhinna nigbati o mu ki …obinrin naa tẹtisi fun iṣẹju kan, si awọn ijiroro rẹ (eyiti a paṣẹ fun wa lati wo lulẹ), nigbati o tẹtisi.

“Nisisiyi, wo nihin, ijọsin jẹ bẹ-ati-bẹ. O ti fi idi mulẹ fun igba pipẹ. A jẹ ọkan ninu awọn ijọsin atijọ julọ ni orilẹ-ede naa. Olori ilu naa lọ.” Emi ko bikita ohunkohun ti o ba jẹ, wo. Ti o ba tako Ọrọ Ọlọrun, ki iwọ naa tako o. Ọta rẹ niyẹn. Ohunkohun ti o lodi si Ọrọ naa ni ọta rẹ.

Ohun gbogbo ti o wa fun Ọrọ ni arakunrin rẹ. Oun jẹ apakan rẹ.

64 Kiyesi, o fa iboju Mimọ kuro, lati ri ohun ti ibalopọ jẹ gaan; gbeyewo, ohun ti ifẹkufẹ yoo ṣe. O yọ Iboju naa kuro loju, ohun mimọ ti Ọlọrun ti fi si oju rẹ. O fẹ imọ, lati mọ ohun ti o jẹ; nitorinaa o fa Iboju kuro lati wo ohun ti o jẹ. O tẹtisi eṣu, si ṣe akiyesi ibi ti o fi si.

Wọn ti ṣe nkanna ni gbogbo igba kọọkan latẹyin wa, wọn a ma tẹle ọgbọn aye; o si ti kọ ijọba Satani bayi, imọ, irugbin rẹ ti o gbin, o si ti sọ aye di Edeni iku.

65 Bayi ṣe akiyesi. Nisisiyi wo Ifihan kẹta, igba Ijọ Laodekia. O ronu ninu ọkan rẹ.

Bayi ṣe akiyesi. Oun, Efa, ni ayaba Satani. Kiyesi, Satani, ejò, de ọdọ Efa ki Adamu to de ọdọ rẹ. Se ẹ ri? Iyẹn tọ. Nitorina o tan-an, wo; nitorinaa Satani, ejò, jẹ ọkọ Efa ṣaaju ki Adamu to mọ. Wo o, o tan-an. Bibeli sọ pe o ṣe, o si mọ pe ihoho ni ohun wa nigbana. Wo?

66 Bayi, wo Igba ijọ Laodekia. Oun, Efa, joko bi ayaba Satani. “O jẹ ọlọrọ ninu awọn ẹru ti aye; afọju,

onihoho lẹẹkansii, ko si mọ,” gẹgẹ bi o ti ri ninu Edeni Ọlọrun. Ṣugbọn nisisiyi, kii ṣe nitori Iboju Mimọ wa lori oju rẹ, ṣugbọn iboju ifẹkufẹ. Bẹ, o mu Iboju Mimọ ti Ọlọrun kuro, o si fi iboju ti imoye wọ, fun ifẹkufẹ. Bayi o ni iboju ifẹkufẹ, ti o fi di “afọju” ti o le ri pe ẹṣẹ ni. O wa ni “ihoho” ni ita, “ko si mọ.” O ṣe panṣaga ni ita. Awọn obinrin ti o n wọ awọn ṣòkòtò kukuru wọnyi, ni oju Ọlọrun, jẹ aṣewo, “ti ko si mọ.”

67 Kiyesi, wo awọn obinrin wa. Ni bayi, ti o ba fẹ ri ipo ti ile ijọsin wa, kiyesi bi awọn obinrin ṣe n ṣe. Obinrin ma n ṣe aṣoju ijo nigbagbogbo. Ninu Edẹni Satani, ti ẹṣẹ ati aigbagbọ, ibajẹ ẹsin; ijọba arekereke. Dipo gbigba Ọrọ Ọlọrun, wọn ti mu ẹkọ ọgbọn ti eniyan. Dipo gbigba Ijọ tootọ naa, wọn tẹle eto eniyan, wọn si n mu wa si ori nla kan.

68 Bayi kiyesi, ìdíbàjẹ aiṣẹ. Maṣe padanu eyi bayi. Ijọ ti n lo iboju ifẹkufẹ yii. Ṣe akiyesi ohun ti o ṣe si i. O ti yii pada lati aiṣẹ si imọ aye. Se ẹ ri? Iboju Mimọ, o jẹ alaiṣẹ; pẹlu ibori ifẹkufẹ, o jẹ onimọ aye. O mọ pe o dun. O mọ ohun ti o n ṣe, wo. Eso ni, igi ti o wuni, ti nsọ ni d'ọlọgbọn. Wo? O yipada kuro ninu aiṣẹ si imọ, lati iwa mimọ si ẹgbin ati ifẹkufẹ, ati lati Iye si iku.

Ijọba yii ni lati ku. Ijọba yii yoo ku! Ọlọrun Ọrun yoo pa a run kuro lori ilẹ.

69 Kiyesi, ninu ibajẹ yii, o ti yipada lati ọkunrin si obinrin, ati lati obinrin si ọkunrin, “ko si mọ.” Ti iwọ ba kiyesi awọn eniyan wa ti ode oni, wa ri pe abájáde gidi lati Edẹni ti Satani ni eyi.

70 Kiyesi, Efa ni Satani lo lati jẹ ki Adamu d'ẹṣẹ nipasẹ agbara ifẹkufẹ rẹ. Ohun to n ṣe loni naa niyẹn. Kiyesi, irun gige, oju kíkun, aṣọ ifẹkufẹ, wo, o n ṣe bẹ, laimọ pe gbogbo awọn nkan wọnyẹn tako Ọrọ Ọlọrun. Gige irun ori rẹ sọọ di obinrin itiju, panṣaga. Wiwọ ṣòkòtò kukuru sọọ di ẹni itiju. Wiwọ awọn aṣọ onifẹkufẹ sọọ di panṣaga. “Ati pe oun ko mọ,” kii ṣe nitori iwa mimọ ti Ọlọrun; nitori ifẹkufẹ Satani. O fa ki o … O mu ki Adamu rẹ ṣe ifẹkufẹ si i.

71 O bọ́ awọn aṣọ ti Ọlọrun ti wọ fun ni Edeni, fun irin-ajo rẹ ninu aginju yii. O mu won kuro. O bọ ara rẹ silẹ. Ọlọrun fi awọ bo gbogbo ara rẹ; ṣugbọn oun bọ diẹdiẹ ni gbogbo igba, o ti wa pada si ibiti o wa ni ibẹrẹ.

Nisisiyi o ti mu ki Adamu rẹ wọ awọn aṣọ isalẹ rẹ. Ti ọkunrin ba wọ awọn ṣokoto kekere wọnyi, ki o jade nihin, Emi ko ro pe iwa ọkunrin pupọ wa ninu rẹ. Ọkunrin bi obinrin ni. Wo? Wo, o ti jẹ ki Adamu rẹ ma huwa bi obinrin, to n wọ awọn aṣọ isalẹ obinrin. O rii ohun ti oun le ṣe nibi yii nigbati oun ba bọ gbogbo aṣọ yatọ si awọtẹlẹ rẹ. Iyẹn ni awọn ṣokoto kukuru. Dajudaju, iyẹn jẹ aṣọ awọtẹlẹ obinrin, Adamu rẹ si ti n wọ wọn bayi. Gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun ṣe sọ, “Ohun irira ni fun obinrin lati wọ aṣọ ti o jẹ ti ọkunrin, ati ki ọkunrin wọ aṣọ ti o jẹ ti obinrin,” lati inu Ọrọ ojulowo. Ronu nipa rẹ!

72 Nisisiyi, o ti n wọ awọn yẹti rẹ pẹlu. Ọkunrin na sọ irun rẹ di gigun bi ti obinrin, o si n ya s'isalẹ bẹ. Ọkan ninu awọn ohun irira julọ ti Mo ti rii ni ki awọn ọmọdekunrin wọnyi loni jade pẹlu yẹti ati irun didi bi eleyi, wọn a tun ma da ọda si irun didi, tabi ki wọn ti bo. Iwọ ọkunrin bi obinrin! Iyẹn jẹ ohun ẹru kan lati sọ lati ori pẹpẹ, ṣugbọn idajọ bẹrẹ ni ile Ọlọrun. Iwọ ko paapaa mọ boya o jẹ ọkunrin tabi obinrin. Ati fi ye mi pe awọn Ẹgbẹ ọmọ ogun Amẹrika ma to ma wọ ṣòkòtò kukuru. Iyẹn tọ. Wo ohun ti idibajẹ na jẹ? O jẹ awọn aṣọ ti obinrin; o n wọ yẹti rẹ.

73 Ni ọjọ kan Mo lọ si ile Howard Johnson; kii ṣe eyi to wa nibi, ṣugbọn ọkan ni opopona ti o jade. Mo kan joko ni iyalẹnu ni. Ọmọdekunrin kan wa kọja, o la ẹnu rẹ ṣilẹ. Irun dudu ni apa kan bayi, o tun ya bayi; ki o si fi ohun yiyi si inu rẹ, o si yi i ka ni ayika, titi de ori oju rẹ; nwa jade ni oke ti awọn oju rẹ, lilọ ni ayika. Oju mi ri ibajẹ! Wo, oun ko ni gbagbọ. O le ṣe afihan pe oun jẹ ọkunrin, ṣugbọn ninu ẹmi rẹ abo ni. Ko mọ iru ẹgbẹ ile ti o jẹ. Iyẹn tọ. Bawo ni a ti daru to!

Ohun ti Satani ma nṣe niyẹn. O ma n ba awon orile-ede jẹ. O ma n ba ijọ jẹ. O ma n ba awon eniyan jẹ. O jẹ ẹlẹtan, oluyipada ojulowo Otitọ.

Ọlọrun ṣe ọkunrin ni ọkunrin. O ṣe obinrin ni obinrin. O si wọ aṣọ ti o yatọ fun wọn, o si pinnu fun wọn lati wa bẹ, ati lati huwa bẹ; ọkan jẹ abo, ekeji jẹ akọ. O ya Adamu sọtọ ninu ọgba Edeni, o si ṣe eyi, ya Efa kuro ninu rẹ.

74 Bayi ọkunrin n wọ yeti obinrin; obinrin ge irun ori rẹ bi t'ọkunrin, ọkunrin si gbiyanju lati ṣe irun rẹ bi t'obinrin. Ṣe ẹ ri? Obinrin wọ awọn aṣọ ita ọkunrin, ọkunrin naa wọ awọn aṣọ awọtẹlẹ obinrin. Bayi, iyẹn dun leti bi ohun ti ko mọ, ṣugbọn Emi sọọ bẹ yẹn. O jẹ Otitọ Ihinrere pipe. Ti o ko ba mọ, a jẹ pe nkan kan ṣe ọ; boya o fọju tabi o ti de ita ri. Ọkunrin ati obinrin na ro pe o tọ, wọn ba lọ bẹ.

Awọn obinrin sọ pe, “wo, ayika gbona!”

Awọn ara ilu Apache atijọ ti o wa nibe yoo jẹ ki oju ti ẹ. Bi ayika ba ṣe gbona sii, bẹ ni wọn wọ aṣọ pupọ si, lati pa oorun mọ kuro lọdọ wọn; oh, jẹ ki wọn lagun, nitorinaa o le ni imuletutu bi wọn ti n rin. Wo? Wọn

duro taara nita gbangba labẹ oorun.

75 Iwọ ko le duro ti ohunkohun bẹ; ara rẹ yoo jona. Ṣugbọn, o rii, iyẹn ni ohun ti o pe ni ẹkọ giga. Imọ-jinlẹ ode oni ti ṣe eyi. Ah! Nibẹ ni o wa, "ihoho," ni Laodekia, "ko si mọ."

O wa ni ihoho ni Edeni. Ṣe ẹ ri awọn ijọba mejeeji bi o ṣe jọ ra wọn? Ọkan jẹ ti ẹṣẹ ati iku; ekeji ni Iye ati ododo. Nibẹ o wa pẹlu Iboju Mimọ. Awọn mejeeji wa ni ihoho; wọn kò mọ̀. Wọn ko mọ nkankan nipa rẹ, nitori a fi ẹmi Ọlọrun bò wọn.

Nihin ifẹkufẹ ni iboju wọn, wọn si nwo ara wọn si … Wo, Adamu le wo Efa tẹlẹ, ko si mọ pe o wa ni ihoho. Ṣugbọn ni bayi pẹlu iboju ifẹkufẹ yii, obinrin ko ṣe akiyesi pe oun wa ni ihoho, ṣugbọn o ṣe labẹ iboju-ifẹkufẹ yii lati jẹ ki eniyan wo o. Idi kan ti o fi n ṣe niyẹn. Iwọ ko gba iyẹn gbọ, ṣugbọn o ṣi nṣe bakanna, ọkunrin si n wo. O si rii pe obinrin dun wo pupọ, titi o fi bẹrẹ si wọ aṣọ obinrin si ara rẹ.

76 Ah, ibajẹ ni eyi! Iru ọjọ wo ni eyi! Akoko wo ni a wa … Igba ẹtan bi eyi! Ha, gbogbo nkan wọnyi, "ko si mọ," ẹmi abuku pipe wa ninu ọkunrin naa. O wọ iboju ifẹkufẹ Satani, ati obinrin naa pẹlu. O jẹ ẹmi eṣu ti awujọ nla kan. Wo, wọn ko mọ, ṣugbọn wọn jẹ eto eniyan. Awọn obinrin to wọ ṣòkòtò kukuru na jẹ ara ijọ kan. Ọkunrin ti o wọ aṣọ bẹ yẹn na wa lara igbimọ kan. Emi yoo fun ọ ni kukuru rẹ, B.S.S., Awujọ Arabinrin Nla, ohun ti wọn jẹ niyẹn. Jade kuro nibẹ, awujọ awọn ọkunrin bi obinrin, pẹlu awọn sokoto kukuru wọn, nkan ti idọti. I—I …

77 Ọkunrin, o le ma gba pẹlu mi lori eyi, ṣugbọn Otitọ ni. O ti di ẹni ibajẹ o ko si mọ. Iwọ kii ṣe bi ọkunrin mọ. Ṣe ẹ ri, o ti wa rọ; ati pe, ọmọkunrin wọn, ki yoo jẹ nkankan si wọn mọ; awọn ọkunrin, ati awọn obinrin, pẹlu. Wọn jẹ awujọ kan. Igbimọ kan wa. Kilode? "Johannu, ara ile keji, wọ ṣòkòtò kukuru, nitorina kilode ti emi ko le ṣe? Luella fẹ ki n wọ wọn nitori Johannu wọ wọn, ni ile keji. Ati pe, ti Susie Jane ba le wọ wọn, nitorinaa Martha Jane le wọ wọn, tabi Susie Lou," tabi ohun ti orukọ ba jẹ, wo. Wo, o jẹ awujọ kan. O jẹ agbajọpọ kan. Iwọ jẹ ara wọn nipa ẹmi, o ko si mọ.

78 Ti o ba si ri bẹ, a si ti ri pe bẹẹni, nitorinaa o ti fọ l'oju. O ko ri awọn ẹyamẹya wọnyi ti Satani ti tan ọ sinu wọn. O si jẹ ibajẹ ojulowo Ọrọ Ọlọrun, ati Ijọba Rẹ, ati ero Rẹ fun awọn ọmọ Rẹ. Satani ti tan awọn ọkunrin ati obinrin sinu nkan wọnyi, wọn ko si mọ. Ibajẹ!

Kii ṣe ọmọ Ọlọrun mọ! Orisirisi oruka ati yẹti ni oju rẹ, pẹlu ṣokoto penpe, ni ita gbangba; ọmọkunrin Ọlọrun, diakoni ni ile ijọsin kan, oluso-aguntan kan ni ibi ipade? Rara, iyẹn kii ṣe ọmọkunrin Ọlọrun. Ko wa nipasẹ Ayẹwo ironu Ọlọrun. Oun ko ni jẹ wọ awọn aṣọ obinrin naa; o daju pe kii yoo ṣe; bẹni obinrin kii yoo wọ awọn aṣọ ọkunrin naa. Ṣe ẹ ri, kii ṣe ọmọkunrin Ọlọrun. O jẹ ọmọkunrin Satani, ati ọmọbinrin Satani. Ohun ti o le lati sọ!

79 Satani ti gba agbaye yii, o ti sọ di ijọba rẹ; nipasẹ ipinnu ara ẹni, eniyan le yan fun ara wọn iru igbesi aye ti wọn fẹ. Ati pe eyi fihan ohun ti o wa ninu ọkan rẹ. Ṣe ẹ ri? Ohùn rẹ … Ṣe o mọ nkan? Awọn iṣe rẹ n pariwo tobẹ, o borì ohun rẹ. Eh-en!

Jẹ ki n lọ sọdọ ọkunrin kan. Ati sọ pe, "Oh, I … Gbogbo wa jẹ Kristiẹni. A ma n lọ si ile ijọsin." Ti awọn aworan obinrin onihoho si wa ni gbogbo ogiri ọfiisi rẹ? Hun! Ohunkohun ti o ba sọ fun mi, Emi yoo mọ ju bẹ lọ; ati iwọ na.

Jẹ ki obinrin sọ pe Onigbagbọ ni oun, pẹlu irun kukuru? Huh-hun! O mọ ju bẹ yẹn lọ, wo. Bẹẹni, sir. Jẹ ki o sọ pe Onigbagbọ ni oun, ti o wọ ọda oju ati atike, ati ṣòkòtò penpe, ko si sọ pe onigbagbọ ni oun? O mọ ju bẹ lọ. Ọrọ Ọlọrun kọ ọ ju bẹẹ lọ. Ọrọ naa sọ pe oun ko le ṣe bẹ ki o si jẹ Onigbagbọ. Obinrin naa paapaa jẹ ẹni itiju, ati gbogbo ẹ. Bawo ni Ọlọrun yoo ṣe fi ohun itiju sinu Ijọba Rẹ? Rara, sir, rara. Rara, sir. Funrara wọn, wọn ṣe afihan ifẹ wọn.

80 O ko le mu ẹiyẹle lati jẹ pẹlu afárá, ko ṣe ṣe rara. Adaba ko ni orònro kankan. Ko le jẹ ẹran atijọ kan kan. Ti o ba jẹ, yoo ku, o si mọ bẹ. Ṣugbọn afárá le jẹ ohunkohun ti o fẹ. Ṣe ẹ ri? O ni òronro.

Nitorina o ri pe, bẹẹni aiye ṣe ri loni, ohun kanna, "Wọn wa ni ihoho, afọju, wọn ko si mọ."

81 Satani ṣe nipasẹ ifẹkufẹ obinrin fun imọ, fun ibalopọ, eyiti o yan nipa yiyan tirẹ. Nisisiyi ṣe akiyesi, Efa ni o fa Adam lọ si aṣiṣe, ati pe obinrin ni o kọkọ bọ aṣọ rẹ kuro ki Adamu rẹ to bọ aṣọ tirẹ. Ṣe ẹ ri? Obinrin naa ni, nigbagbogbo. O ti wa bẹ. Bakanna sì ni.

Ile ijọsin ni o ma n mu eniyan ṣina. Kiyesi, ile ijọsin ni o ma n ṣe amọna ọkunrin ti o fẹ jẹ ọmọ Ọlọhun. Obinrin naa ni, ile ijọsin. Kii ṣe Bibeli, Ọlọrun, nitori Bibeli jẹ ọkunrin. Ha, bẹẹni, "Ọrọ naa di ara," Oun si jẹ Ọkunrin. Ṣe ẹ ri? Bibeli jẹ ọkunrin; ijọ ni obinrin. Ṣe ẹ ri? Kii ṣe Bibeli ni o mu ọkunrin naa ṣina. Ijo ni o mu u ṣina. Ijọ lo fi ihoho ba lọ, kii ṣe Bibeli. Ṣe ẹ ri? Rara. Bibeli sọ fun u pe o wa ni ihoho. Bẹẹni, sir.

Bayi ṣe akiyesi bi, nipa ibalopo, ifẹ ti ibalopọ, o ṣe ifẹkufẹ fun imọ, lati mọ ohun ti eyi jẹ, ati boya eso yii dara tabi ko dara. O si ṣe bẹ.

82 Ọlọrun yoo gba pada ni ọjọ kan, nipasẹ Ọkunrin kan. Obinrin lo jọwọ rẹ. Ṣugbọn Ọkunrin kan lo ti rà pada; Ọkunrin naa, Jesu Kristi, ti o jẹ Ọrọ naa.

Lẹhinna kini o jẹ? Kiyesi, ni ipari. Ni igba diẹ sẹyin, Mo ṣe alaye yii nibi. Mo ni to oju-iwe mẹrin tabi marun sii nibi, ... ti awọn Iwe Mimọ ati awọn nkan ti Mo fẹ tọka si. Ṣugbọn, tẹti. Jẹ ki a mu ẹnu duro, pẹlu eyi.

83 Ranti, nigba diẹ sẹhin, Mo n kọ yin nipa Awọn ipè Meje, Ajọdun Awọn ipè, ati bẹbẹ lọ. Mo si sọ pe, “Ajọdun ọjọ kẹjọ wa.” Nitorinaa, ọjọ keje yoo kẹhin, iyẹn yoo jẹ Ẹgbẹ̀rún Ọdun. Ṣugbọn ajọdun ọjọ kẹjọ wa; eyiti, ti o ba jẹ ọjọ kẹjọ, ti a si mọ pe ọjọ meje lasan lo wa, yoo jẹ ki o di ọjọ akọkọ lẹẹkansi, a pada si ọjọ akọkọ. Lẹhin naa, lẹhin ti Ẹgbẹrun Ọdun naa ba pari, nigbana ni Edeni ti o fẹsẹmulẹ yoo tun wa. Ijọba nla Ọlọrun yoo pada si ipo. Nitoripe Jesu bori Satani, ni ọgba Gẹtisemani, o si gba Edeni pada; eyiti, O ti lọ mura rẹ silẹ ni Ọrun, lati pada lẹẹkansi, ni Ọrun. O sọ pe, “Ẹ maṣe jẹ ki ọkan nyin dàru.”

84 Nigbati O wa nihin ni aiye, O sọ pe, “Ẹnyin ará Ju, ẹ ti gba Ọlọrun gbọ. Bayi, Mo mọ pe ẹ ti ba orukọ mi jẹ,” O sọ. “Wọn si sọ pe Emi jẹ bayi, tabi ohun miiran. Ṣugbọn, ẹ ti gba Ọlọrun gbọ; gẹgẹ bi ẹ ti gba Ọlọrun gbọ, ẹ gba Mi gbọ pẹlu.” Oun ni Ọlọrun, ti O farahan. Ṣe ẹ ri? “Gbagbọ pẹlu ninu ...”

85 “Ninu ile Baba mi ọpọlọpọ …” Tabi, “Ninu eto-ọrọ Baba mi, awọn aafin pupọ nbẹ ninu ipinnu Baba mi. Emi yoo lọ ṣeto aaye kan.” Wo bi o ti gun to, o to ọgọrun mẹẹdogun onigun mẹrin! Tọ, nibo ni o wa? O ti lọ ṣeto rẹ. Oun ni Eleda. Oun ni o da gbogbo wura yẹn. Awọn opopona naa jẹ sihin. Oun ni Eleda. O n pese aye. Ni ipari ninu Iwe Ifihan 21, o sọ pe, “Emi Johanu si ri Ilu mimọ naa, Jerusalemu Tuntun, ti n sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun lati Ọrun wá.”

“Ko si okun mọ; ọrun akọkọ ati aiye akọkọ ti kọja lọ.” Kini awọn ọrun akọkọ wa? Ohun ni Ẹgbẹrun Ọdun naa. Kini aiye akọkọ? Eleyi ni. Yoo tunṣe. Gẹgẹ bi a ti ṣe iribọmi fun aiye yii nipasẹ Noa, ni igba ọjọ iwaasu rẹ; ti a sọ aiye yii di mímọ nipasẹ Kristi, bi O ti ta ẹjẹ Rẹ silẹ; Yoo tunṣe, lati mu gbogbo awọn kòkòrò àrun ati ohun gbogbo kuro ninu rẹ, ni isọdọtun igbẹhin, pẹlu baptisi Ina ti yoo pa gbogbo kokoro, gbogbo aisan, gbogbo arun, gbogbo ẹgbin ti o wa lori ilẹ.

86 Yoo bu jade, yio si di Aiye Tuntun. “Mo si ri Ọrun Tuntun ati Aye Tuntun. Ọrun akọkọ, ayé akọkọ yii, ti kọja lọ; kò sì sí òkun mọ́. Emi Johanu si ri Ilu mimọ, Jerusalemu Tuntun, ti o sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun lati Ọrun wá.” Nibẹ l'Ọlọrun yoo wa pẹlu awọn abuda otitọ Rẹ, awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin, nibiti O le ṣe ajọṣepọ pẹlu wọn ni iwa mimọ, ti wọn ko le ri ẹṣẹ. Ki yoo si ẹṣẹ mọ lati ibẹ.

Jẹ ki a tiraka; maṣe jẹ ki a tan ọ jẹ ni oni, ṣugbọn, “tiraka lati wọle ni ẹnu-ọna.”

“Nitori gbogbo awọn ti yoo kun ni yoo jẹ awọn panṣaga, awọn onifẹkufẹ.” “Ẹnikẹni ti o wo obinrin lati ṣe ifẹkufẹ si i ti ṣe panṣaga pẹlu rẹ.” Gbogbo wọn pẹlu … awọn obinrin itiju ni yoo wa ni ita, awọn ọkunrin itiju, ati bẹbẹ lọ.

Awọn ti a ti ràpadà, ti o wa ninu Iwe Ọdọ-Agutan ti Iye, ni yoo wọle ni ẹnu-bode. Nitorina tiraka, ọrẹ; maṣe tan ara rẹ jẹ ni ọjọ ikẹhin yii.

87 Akoko nla ni eyi. Gbogbo eniyan ni owo. Gbogbo eniyan le ṣe eyi, gbogbo eniyan si le ṣe iyẹn, ti owo nṣàn ni gbogbo ọna, ati awọn ọkọ nla, ati ohun gbogbo. Ko ni si ọkan ninu awọn nkan yii ni Ilu yẹn. Ko ni si ọkọ ayọkẹlẹ kan, ọkọ ofurufu kan. Rara. Yoo jẹ ọlaju iru miiran. Yoo jẹ ọlaju ti kii ṣe ti imọ, kii ṣe ti imọ-jinlẹ, ṣugbọn ti aiṣẹ, ati igbagbọ ninu Ọlọrun alãye.

Ẹ jẹ ki a lakaka lati wọnu Iyẹn. Nitori gbogbo ipinnu mi niyẹn, lati wọnu Ilu yẹn lọjọ kan; kin si wo ẹhin, kin ri pe gbogbo yin wa pẹlu mi, ba ti nkorin, “awọn eniyan mimọ n yan wọle.” Nigbati awọn eniyan mimọ ba n wọle, Mo fẹ ki Oluwa ka mi mọ wọn.

Ẹ jẹ ki a gbadura.

88 Baba ọwọn ti n bẹ li Ọrun, bi awọn ọjọ ti n pari, a si rii pe o n sunmọ, ileri naa sunmọle. Ọlọrun ọwọn, a gbadura pe Iwọ yoo fi si ọkan wa, ki a ma ba ṣe aṣiṣe. Ọlọrun olufẹ, pa ẹri-ọkan wa mọ. Fi iboju Rẹ si okan wa, Oluwa, ki oju wa má ri awọn ohun ti aye, ati awon ohun asan ti aye, ogo asan lati di eni nla kan.

Laibikita bi wọn ti tobi to, gbogbo awọn ọba, awọn ijoye, awọn alagbara, ati ohun gbogbo miiran ni lati parun, ati pe wọn kii yoo dide ni ajinde akọkọ. Nitoriti a kọ ọ pe, “Alabukun ati mimọ ni ẹniti o ni ipin ninu ajinde akọkọ, ti iku keji ko ni agbara lori rẹ.” Ọlọrun! “Iku keji,” iku ẹmi, “ko ni agbara”; a ti ràá pada!

89 Iwọ Ọlọrun, lati ronu pe ọkan ninu awọn wakati wọnyi, ọkan yoo lọ ṣe ibẹwo si ekeji, a o si mu lọ sogo.

"Ẹni meji lori ibusun kan; yoo mu ọkan, yoo si fi ọkan silẹ. Ẹni meji ni pápá; Emi yoo mu ọkan, fi ọkan silẹ."

Ọlọrun, ran wa lọwọ lati jẹ mimọ ni oju Rẹ, Oluwa, laibikita ohun ti eniyan le ronu nipa wa, ohun ti awọn eniyan miiran sọ. Oluwa, jẹ ki ... awọn ibaraẹnisọrọ wa jẹ mimọ. Jẹ ki mu dun pẹlu Ọrọ Ọlọrun; to jinna to bẹ, Oluwa, ti ko ni si ẹtan ninu wa. A n bẹbẹ fun awọn aṣiṣe wa, pe ki Ẹjẹ Jesu Kristi duro larin awa ati Ọlọrun, pe Oun yoo wo wa nipasẹ Ẹjẹ Jesu; kii ṣe lori ododo ti ara wa, tabi ẹni ti awa jẹ, ohun ti a ti ṣe, ṣugbọn lori awọn ẹtọ Rẹ nikan. Ọlọrun, fifun wa!

90 Ki ẹnikẹni ti o joko nihin lalẹ yii ti o gbọ Ifiranṣẹ naa, maṣe jẹ ki ọkan ninu wọn sọnu, lati ọmọde kekere si ẹni ti o dagba julọ. Ki ifẹ mimo wọn ki o jẹ fun Ọlọrun ati Ọrọ Rẹ nikan. A ko mọ wakati ti O le farahan, tabi wakati ti O le pe wa lati dahun nibe ni Idajọ. A ko mọ wakati ti O le ṣe, ti Yoo sọ pe, "O to akoko lati wa si ile. O ni lati lọ." Ọlọrun, ran wa lọwọ lati wa ni mimọ. Ṣe bẹ fun wa, Oluwa.

Ki a wa laaye titi Wiwa Oluwa, ti o ba ṣeeṣe. Ki a ṣe gbogbo ohun ti a le ṣe pẹlu ifẹ ati oye, oye pe Ọlọrun n wa aye loni, O n wa gbogbo awọn agutan ti o sọnu. Oluwa, jẹ ki a ba wọn sọrọ pẹlu adura didun ti ifẹ ati Ọrọ Ọlọrun, ki a le ri eyi ti o kẹhin, ki a le lọ si Ile, ki a si jade kuro ni Eden ti Satani yii.

91 Edẹni ti a kọ sori ifẹkufẹ, ati awọn obinrin ẹlẹwa, bi a ṣe npe ni agbaye, pẹlu awọn ipolowo wọn lori ibẹ, "A ṣe ikede, ati pe a fẹ ki awọn ọmọkunrin wa pẹlu jaamu loju wọn, ati awọn ọmọbinrin ẹlẹwa ti o wọ ṣòkòtò penpe." lori awọn redio ati tẹlifiṣọnu wa; ati gbogbo iru ẹgbin lati Hollywood; gbogbo iru awọn aṣọ ẹlẹgbin fun awọn obinrin. Awọn ọkunrin idibajẹ ti n wọ aṣọ obinrin, wọn ṣe irun wọn bi awọn obinrin; ati obinrin bi okunrin.

Ọlọrun, iru wakati buruku ti a n gbe yii! Ha, wa, Jesu Oluwa, wa! Wá, Oluwa! Wẹ wa mọ nipa Ẹjẹ naa. Mu gbogbo ẹgbin ati ete kuro lọdọ wa. Jẹ ki a gbe, Oluwa, jẹ ki a gbe labẹ Ẹjẹ naa, nigbagbogbo, niwaju Rẹ. O jẹ ifẹ ọkan wa, ati ẹbẹ tọkàntọkàn wa.

92 Ọlọrun Olufẹ, ti o dubulẹ lori pẹpẹ yii ... tabi awọn wọnyẹn, ni alẹ oni, nibiti a ti gbe Ihinrere kalẹ. Oluwa, awọn aṣọ-ọwọ ati awọn apo kekere wà nibi yii fun awọn alaisan ati awọn ti o ni ipọnju. Jẹ ki adura igbagbọ, Oluwa, wá lati ọkan wa bayi, ni iwaju Rẹ. Lẹhinna, Oluwa, ti ohunkohun alaimọ ba wa ninu wa, Oluwa, mu wa … mu wa lọ si idajọ nisisiyi; awa si bebe fun aanu. Fi aṣiṣe wa han wa, Oluwa, ki Ẹjẹ naa le wẹ wa mọ. Mu awọn alaisan wọnyi larada, Baba, ibikibi ti wọn lọ. Jẹ ki o ri bẹ, Baba.

93 Fun wa ni ipinnu lati sin Ọ, Iwọ nikan ṣoṣo. Fifun wa, Oluwa.

Dáàbò bò awọn eniyan ayanfẹ wọnyi ti wọn lọ si ile.

A dupẹ pe Ẹ ti mu awọn eniyan larada. Mo gbadura fun ọmọdekunrin Arabinrin Shepherd ati Arakunrin Shepherd ti o farapa lori kẹkẹ, pe ki ohun buburu kankan ma de bẹ; ọmọ kekere ti o gun kẹkẹ rẹ, Mo gbadura pe yoo wa dada. A dupẹ lọwọ Rẹ fun imularada rẹ ti awọn miiran wọnyi ti a ti beere fun. "Awa si mọ pe ohun ti a beere, a ri gba, nitori a ni igbẹkẹle ninu Ẹni ti o ṣe ileri."

Fun wa ni ore-ọfẹ Rẹ, Oluwa, ki o si dari awọn ẹṣẹ wa ji wa, a beere ni Orukọ Jesu Kristi. Amin.

94 Ṣe ẹ fẹran Rẹ? [Ijọ sọ pe, "Amin." — Ed.] Ṣe ẹ gba A gbọ? ["Amin."] Ṣe ijọba Satani ti su ọ? ["Amin."] Ṣe o gbagbọ pe o n bọ si Ẹgbẹrun ọdun, si Ẹgbẹrun ọdun Rẹ; si Edeni Rẹ? ["Amin."]

O gbagbọ pe a ti ṣẹda rẹ loni? Wo, ohun gbogbo da lori awọn ọlọgbọn. Wọn gbọdọ fi idi ohun gbogbo mulẹ pẹlu imọ-jinlẹ ki wọn to gbagbọ.

Ṣugbọn o ko le fi Ọlọrun han nipa imọ-jinlẹ. Igbagbọ lo ma fi gba A, "Nitori ẹni ti o ba tọ Ọlọrun wa gbọdọ gbagbọ pe O wa, ati pe O jẹ olusẹsan fun awọn ti o fi taratara wa a."

Ọlọrun, Emi ko fẹ mọ nkankan bikoṣe Ẹjẹ Jesu Kristi ti o wẹ mi nu kuro ninu ẹṣẹ. Emi ko mọ nkankan bikoṣe Jesu Kristi. Gẹgẹ bi Paulu ti sọ ni atijọ, bẹẹ ni mo sọ ni alẹ yii, "Emi ko mọ nkankan laarin yin, ayafi Jesu Kristi nikan, ati Oun ti a kan mọ agbelebu."

95 Iyẹn nikan ni Mo mọ lati sọ fun ọ. Mo gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan mi (ti mo ba mọ ọkan mi), wípe Bibeli yii ni Ọrọ Ọlọrun pípe ti ko ni abawọn. Nipasẹ Eyi ni Mo wà laaye. Nipasẹ Eyi ni mo duro. Bi n ba si ni ẹgbẹẹgbẹrun aye, Emi yoo fẹ lati fi gbogbo rẹ fun Ọrọ yii, nitori o jẹ Ọrọ ti Jesu Kristi. Emi ko si bikita bi wọn le gbiyanju lati ṣeke rẹ, bi imọ-jinlẹ ṣe n gbiyanju lati sọ pe Ko ṣe gbẹkẹle, ati bẹbẹ lọ. Si mi, Ọrọ yi nikan ni Mo le gbẹkẹle ni aiye yii. Oun ni temi. Mo fẹran Rẹ. Iwọ nko? [Ijọ sọ pe, "Amin." — Ed.]

96 Ti ẹṣẹ kan ba wa ni ọkan rẹ, ti aṣiṣe kan ba wa ninu ọkan rẹ, ti o ba ni ohunkohun, gbadura bayi ki o beere lọwọ fun idariji Ọlọrun. Gbadura fun mi; Emi yoo gbadura fun ọ. Ki Ọlọrun bukun fun ọ, ni adura mi.

Titi a o fi pade! titi awa o fi pade!
Ọlọrun wa pẹlu rẹ titi a o fi tun pade!

Njẹ ẹ fẹran ara yin? [Ijọ sọ pe, “Amin.” — Ed.] Johanne sọ pe, “Ẹyin ọmọ, ẹ fẹran ara yin.” “Ẹ fẹran ara yin, nitori ifẹ á ma bo ọpọlọpọ ẹṣẹ mọlẹ.” Bayi ẹ jẹ ki a bọ ara wa lọwọ.

Ki Ọlọrun wa pẹlu rẹ titi a o fi tun pade!
Titi a o fi pade! titi awa o fi pade!

Bayi, ẹ jẹ oninuure si ara yin. Ṣaanu fun gbogbo eniyan. Huwa daradara si aladugbo rẹ. Pa ara rẹ mọ lai labawọn titi Jesu yoo fi de.

… ẹsẹ;
Titi a o fi pade! titi awa o fi pade!
Ọlọrun wà pẹlu rẹ titi a o fi tun pade!

97 Njẹ iwọ fẹran Rẹ? [Ijọ sọ pe, “Amin.” — Ed.] Adurà mi niyẹn. Ẹyin ẹ gbadura fun mi; Emi yoo gbadura fun yin. Mo ni lati pada si Tucson bayi. Mo gbadura pe Ọlọrun yoo bukun fun gbogbo yin. Mo n lọ si ilu Kanada lati ibẹ, ma pada si Ilu Kolorado; yipo bẹ yẹn, ṣe ẹ ri. Titi …

Arakunrin Tony wa nibẹ, ohun nla kan si ti ṣẹlẹ. Ni ilu Fatikani gangan, ni Romu, wọn n bere fun isọji, ipade, pe ki n wa sibẹ fun isọji ni Romu, ni Romu. O ṣẹṣẹ pada de lati ibẹ ni. Awọn eniyan naa wa papọ. Wọn ni gbagede nla nibẹ, to le gba ẹgbẹẹgbẹrun ati ẹgbẹẹgbẹrun, wọn si fẹ ki n wa fun isoji kan. Wọn fẹ ri ogo Oluwa ninu iṣẹ-iranṣẹ naa. Emi ko mọ. Mo ni lati gbadura nipa rẹ, lati ri ohun Oluwa yoo sọ fun mi. Ha, temi! Ranti, gbadura, gbogbo wa lapapọ. A n ṣiṣẹ …

A nreti bíbọ Olugbala wa Alábukun,
Kiyesi i, awọn ewe ọpọtọ naa ti n di awọ ewe gangan bayi;
Ihinrere ti Ijọba Rẹ ti lọ si gbogbo orilẹ-ede;
A sì ri pe a ti sunmọ òpin.

Ṣe bẹẹni? [Ijọ sọ pe, “Amin.” — Ed.]

Nitorina ẹ jẹ ki a kede Iroyin bibọ Rẹ pẹlu ayọ,
Sọ nipa bibọ rẹ ni ògo fun gbogbo eniyan;
Ẹ dide, ẹnyin eniyan mimọ Oluwa, e ma ṣe sun nigbati opin n sunmọ,
Ẹ jẹ ki a mura silẹ fun ipe ikẹhin naa.

98 Yoo yipada ni iwọ-oorun lẹẹkansi, ọkan ninu awọn ọjọ wọnyi, ṣaa ranti. O daju pe bẹẹni. Bẹẹni. Titi di igba naa:

Mi Orukọ Jesu pẹlu rẹ,
Ọmọ ibanujẹ ati egbé;
Yoo jẹ ayọ ati itunu fun ọ,
Mu, ni ibikibi ti o ba nlo.
Orukọ Iyebiye (Orukọ iyebiye), Iwọ ti dun to!
Ireti aye ati ayo Orun;
Orukọ Iyebiye, bo ti dun to! (bo ti dun to!)
Ireti aye ati ayo Orun.
Ti tẹriba ni Oruko Jesu,
Wolẹ ni ẹsẹ Rẹ,
Ọba awọn ọba ni Ọrun a o de ni ade,
Nigbat'ajo wa ba pari.
Orukọ Iyebiye, o ti dun to!
Ireti ayé ati ayọ Ọrun;
Orukọ Iyebiye, o ti dun to!
Ireti aye ati ayo Orun.

99 Nisisiyi, lori ẹsẹ ti o kẹhin yii, jẹ ki a kọrin pẹlu itẹriba ọkàn bayi.

Mu Orukọ Jesu pẹlu rẹ,
Bi aabo kuro ninu gbogbo ìdẹkùn;
Ti idanwo ba si yi ọ ka, (awọn nkan ti ijọba Satani wọnyi)
Kan mi Orukọ mimọ yẹn ninu adura.

Gbogbo ẹ niyẹn; wa fi silẹ bẹ. O nsise. Mo ti dan wo. Sa gbagbo bayi, 'tori o ma sise. Sa simi Oruko mimo Re ninu adura.

… Orukọ Jesu pẹlu rẹ,
Bi ààbo kuro ninu gbogbo ìdẹkun;
Nigbati awọn idanwo ba yi ọ ka, (Kini o yẹ ko ṣe nigbana?)
Kan mi Oruko mimo yen ninu adura. (Iboju Naa yoo bo oju rẹ nigbana.)
Orukọ Iyebiye (Orukọ iyebiye), o ti dun to!

Ireti ayé ati ayọ Ọrun;
Oruko Iyebiye, o ti dun to!
Ireti aye ati ayo Ọrun.

Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba, bi Mo ṣe ma pe Arakunrin Beeler pada wa si ori pẹpẹ. [Arakunrin Branham bẹrẹ si kọ “Mu Orukọ Jesu Pẹlu Rẹ” labẹ ohun — Ed.]

Sa mi Oruko mimo Rẹ ninu adura.

Arakunrin Beeler, ẹ fun wa ni ibukun ipari. Ẹ gbadura ibukun fun wa.

Orukọ Iyebiye,
Ireti ayé ati ayọ Ọrun;
Orukọ Iyebiye (Orukọ iyebiye), o ti dun to!
Ireti aye ati ayo Ọrun.

100 Bayi pẹlu ori wa ti a tẹriba, ti ọkan wa si tẹriba. Arakunrin Beeler, ọkan ninu awọn alabaṣiṣẹpọ wa nihin, Arakunrin Estle Beeler, arakunrin Onigbagbọ to dara, ọkunrin oloootọ. Emi yoo beere pe ki o gbadura ipari fun wa lalẹ yii. Ọlọrun bukun fun ọ, Arakunrin Beeler.

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info